**NATIONAL OPEN UNIVERSITY OF NIGERIA xxxxxWORKING COPY**

National Open University of Nigeria
Headquarters
14/16 Ahmadu Bello Way
Victoria Island
Lagos

Abuja Annex
245 Samuel Adesujo Ademulegun Street
Central Business District
Opposite Arewa Suites
Abuja
e-mail: centralinfo@nou.edu.ng
URL: www.nou.edu.ng

National Open University of Nigeria

First Printed

ISBN:
All Rights Reserved

Printed by ……………..
For
National Open University of Nigeria

# YOR 351: ÀWỌN Ẹ̀KA ÈDÈ YORÙBÁ
# (DIALECTS OF YORÙBÁ)


**LÁTI ỌWỌ́**

**OLÚWADỌRỌ̀, JACOB OLÚDÁRE**
**B.A.; M.A.; PGDE, PhD (LINGUISTICS)**

**COURSE EDITOR: PROFESSOR OYE TAIWO**

## ÀKÒÓNÚ

**Módù 1: Ẹ̀ka Èdè**

Ìpín 1: Ẹ̀ka-Èdè 1

Ìpín 2: Ìwúlò Ẹ̀ka-Èdè 5

Ìpín 3: Pípẹ̀ka Èdè 9

Ìpín 4: Àlèébù Títẹramọ́ Ẹ̀ka-Èdè 12

Ìpín 5: Àwọn Ọ̀rọ̀ Àìtọ́ Nípa Ẹ̀ka-Èdè 15

**Módù 2: Iṣẹ́ Lórí Ẹ̀ka-Èdè Yorùbá**

Ìpín 1: Adétugbọ (1967) 18

Ìpín 2: Oyèlaran (1976 21

Ìpín 3: Akínkùgbé (1978) 24

Ìpín 4: Awóbùlúyì (1998) 27

Ìpín 5: Adéníyì àti Òjó (2005) 30

**Módù 3: Àlàyé Kíkún Lórí Ẹ̀ka Méje tí Adéníyì àti Òjó Pín Èdè Yorùbá Sí**

Ìpín 1: (a) Ẹ̀ka Ìlà Oòrùn àti (b) Ìwọ̀ Oòrùn 34

Ìpín 2: Ààrin Gbùngbùn 38

Ìpín 3: Àríwá Ìlà Oòrùn 41

Ìpín 4: Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn 44

Ìpín 5: (a) Gúsù Ìlà Oòrùn àti (b) Gúsù Ìwọ̀ Oòrùn 47

**Ìgbéléwọ̀n Akẹ́kọ̀ọ́**

Oríṣi ìgbéléwọ̀n méjì ni o máa ṣalábàápàdé. Àwọn méjèèjì ni Iṣẹ́ Ṣìṣe àti Ìdánwò òpin simẹ́sítà. A ń retí pé kí o ṣe ìdánwò ní òpin abala ẹ̀kọ́ yìí.

**Ìgbéléwọ̀n tí olùkọ́ yòò máàkì**

Ní òpin ìpín kọ̀ọ̀kan, mo ti ṣètò Iṣẹ́ Ṣìṣe fún ọ, o gbọ́dọ̀ gbìyànjú láti ṣe wọ́n nípa lílo gbogbo ìmọ́, ọgbọ̀n àti ìfitónilétí tí o ti gbà nínú ìpín náà. Lórí ẹ̀rọ ìtànẹ́ẹ̀tì ni o ti máa ṣe àwọn Iṣẹ́ Ṣìṣe tí o sì máa gba èsì lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀. Èyí yóò sì fòpin sí pípẹ́ tí èsì ìdánwò máa ń pẹ́ kí o tó tẹ akẹ́kọ̀ọ́ lọ́wọ́. Gbìyànjú láti fi Iṣẹ́ Ṣìṣe tìrẹ sọwọ́ sí ilé-ìwé rẹ ní ọjọ́ tí a polongo rẹ̀ lórí òpó ítánẹ́ẹ̀tì Yunifásítì àti ni Ibi Ìkẹ́kọ̀ọ́ rẹ. Ìdá ọgbọ̀n nínú ọgọ́rùn-ún (30%) ni Iṣẹ́ Ṣìṣe jẹ́ nínú ìgbéléwọ̀n àṣekáagbá rẹ.

**Ìdánwò Àṣekágbá**

Ìdánwò Àṣekágbá jẹ́ ìdá àádọ́rùn-ún nínú ọgọ́rùn-ún (70%) jẹ́ nínú jẹ́ nínú ìgbéléwọ̀n àṣekáagbá rẹ. Bákan náà, lórí ẹ̀rọ òpó ìtánẹ́ẹ̀tì ti Yunifásítì ní o ti máa ṣe ìdánwò gẹ́gẹ́ bí mo ṣe sọ ṣáájú. A óò sì ṣa àwọn ìbéèrè jọ láti inú gbogbo ìpín abala ẹ̀kọ̀. Nítorí náà, a ń retí pé kí o ka ìwé ìdánilẹ́kọ̀ọ́ dáadáa kí àkókò ìdánwò tó dé. Bákan náà pẹ̀lú, ó yẹ kí o mọ́jú tó ìṣàmúlò ẹ̀rọ kọ̀ǹpútà rẹ dáadáa fún àǹfàní ara rẹ.

**Ètò Ìlànà Máàkì Gbígbà**

Àpapọ̀ máàkì fún abala ẹ́kọ́ ni 100%. Ìdá ọgbọ̀n nínú ọgọ́rùn-ún (30%) jẹ́ máàkì fún Iṣẹ́ Ṣìṣe àti ìdá àádọ́rùn-ún nínú ọgọ́rùn-ún (70%) jẹ́ máàkì ìdánwò. Mo gbà ọ̀ ní ìmọ̀ràn pé kí o sa gbogbo ipá rẹ láti ṣàṣeyege nínú Iṣẹ́ Ṣíṣe àti nínú ìdánwò kí o ba lè ṣàṣeyọrí ní ìkẹyìn.

## ÌFÁÀRÀ SÍ KỌ́Ọ̀SÌ YÌÍ

A pín iṣẹ́ yìí sí Módù Mẹ́ta. Módù kọ̀ọ̀kan ní ìpín márùn-ún. Àwọn ohun tí a sọ̀rọ̀ lé lórí ní módù kìn-ín-ní ni: (i) ìtumọ̀ ẹ̀ka-èdè (ii) ìwúlò ẹ̀ka-èdè (iii) bí èdè ṣe ń pẹ̀ka (iv) àlèébù títẹ̀ramọ́ ẹ̀ka èdè, àti (v) àwọn ọ̀rọ̀ àìtọ́ nípa ẹ̀ka èdè.

Ní Módù 2, a ṣe àlàyé lórí iṣẹ́ tí àwọn òǹkọ̀wé ti ṣe lórí ẹ̀ka èdè Yorùbá. A pín Módù kejì sí ìpín márùn-ún: (i) Iṣẹ́ Adétugbọ̀ (1967) (ii) Iṣẹ́ Oyèlaran (1976) (iii) Iṣẹ́ Akínkùgbé (1978) (iv) Iṣẹ́ Awóbùlúyì (1998), àti (v) Iṣẹ́ Adéníyì àti Òjó (2005).

Ní Módù 3, a ṣe àtúpalẹ̀ iṣẹ́ Adéníyì àti Òjó (2005), gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ tí ó kún jù lọ. Ẹ̀ka méje ni wọ́n pín èdè Yorùbá sí. A pín Módù 3 sí ìpín márùn-ún: (i) (a) Ẹ̀ka Ilà Oòrùn àti (b) Iwọ̀ Oòrùn (ii) Ẹ̀ka Ààrin Gbùngbùn (iii) Àríwá Ilà Oòrùn (iv) Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn (v) (a) Gúsù Ilà Oòrùn àti (b) Gúsù Iwọ̀ Oòrùn.

## MÓDÙ I: ẸKA ÈDÈ

Gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe àlàyé lábẹ́ àfojúsùn sí kọ́ọ̀sì yìí, Módù kìn-ín-ní ní ìpín márùn-ún. Ìpín àkọ́kọ́ sọ̀rọ̀ lórí ohun tí ẹ̀ka-èdè jẹ́. Ìpín kejì ṣe àlàyé ìwúlò ẹ̀ka èdè. Ìpín kẹta ṣe àlàyé bí èdè ṣe máa ń pẹ̀ka. Ìpín kẹrin sọ̀rọ̀ nípa àwọn àlèébù tí ó rọ̀ mọ́ títẹramọ́ ẹ̀ka èdè sísọ, nígbà tí ìpín karùn-ún ṣe àlàyé àwọn ọ̀rọ̀ àìtọ́ tí àwọn kan máa ń sọ nípa ẹ̀ka èdè. Ẹ bá wa kálọ nínú ẹ̀kọ́ yìí.

## ÌPÍN KÌN-ÍN-NÍ
## ẸKA ÈDÈ

### 1.0 Ìfáàrà sí ìpín kìn-ín-ní

Àfojúsùn wa ní ìsọ̀rí yìí ni láti sọ ohun tí ẹ̀ka èdè jẹ́. Èyí ni pé ìbéèrè tí a fẹ́ ṣe ìdáhùn rẹ̀ ni pé: Kí ni ẹ̀ka èdè jẹ́ gan-an? A ó bẹ̀rẹ̀ abala yìí nípa ṣíṣe àfiwé èdè pẹ̀lú igi. Nígbà tí àgbẹ̀ bá gbin èso igi, igi yìí á hù jáde lẹ́yìn ìgbà díẹ̀. Nígbà tí igi bá hù jáde, á bẹ̀rẹ̀ sí í dàgbà díẹ̀ díẹ̀. Lẹ́yìn tí igi yìí bá ga sókè, á bẹ̀rẹ̀ sí ní í p'ẹ̀ka. Kí á gbà wí pé igi tí a fi lọ́lẹ̀ yìí ni èdè fúnra rẹ̀, àwọn ẹ̀ka tí ó ń pa sì ni ẹ̀ka-èdè, èyí tí àwọn olóyìnbó pè ní 'Dialects'. Ní ṣókì, a ó ṣàlàyé ẹ̀ka èdè gẹ́gẹ́ bí ìpín tàbí ẹ̀yà kan nínú èdè kan tí ó ní àbùdá tí ó yàtọ̀ nípa ètò ìró, ìhun gírámà àti ọ̀nà gbígbé ọ̀rọ̀ jáde.

### 2.0 Èròǹgbà àti àfojúsùn

Ní ṣókí, èròǹgbà wa fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kìn-ín-ní yìí ni lati sọ ohun tí ẹ̀ka-èdè jẹ́. Àfojúsùn wa sì ni pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè ṣàlàyé ní kíkún ohun tí èdè fúnra rẹ̀ jẹ́ àti ohun tí ẹ̀ka èdè jẹ́ ní kíkún lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí.

### 3.0 Ìbéèrè ìṣàájú

(a) Kí ni ẹ̀ka-èdè?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Ohun àkọ́kọ́ tí a fẹ́ ṣe ní ìpín yìí ni láti ṣe àgbéyẹ̀wò akitiyan àwọn onímọ̀ lórí ohun tí ẹ̀ka-èdè jẹ́. A pe ẹ̀ka-èdè ní ‘dialect’ nínú èdè Gẹ̀ẹ́sì. Àwọn onímọ̀ ìjìnlẹ̀ ṣe àlàyé pé ọ̀rọ̀ yìí jẹ yọ nínú ‘Èdè Gíríkì’ (Greek Language), tí a pè ní ‘Dialecto’, tí ó túmọ̀ sí ọ̀rọ̀-ẹnu, ọ̀nà-ìgbà-báni-sọ̀rọ̀ tàbí ‘àrà ọ̀tọ̀’ nípa ìsọ̀rọ̀. Ẹ̀ka-èdè jẹ́ ìmọ̀ ẹ̀dà-èdè tí ó sọ nípa àwọn ìyàtọ̀ tí ó wà nínú èdè kan nípa bí a ṣe ṣe àtúnpín rẹ̀ sí ìsọ̀rí.

## 4.1 Oríkì Ẹ̀ka-Èdè

Àwọn òǹkọ̀wé, Chambers àti Trudgil (1994: 3) so pé:

> A substandard, low status, often rustic form of language, generally associated with peasantry, the working class, or other groups lacking in prestige… a term which is often applied to forms of language, particularly spoken in some isolated parts of the world.

Ohun tí àwon òǹkọ̀wé yìí so ni pé ẹ̀ka-èdè je ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ àwọn ará oko, àwọn tí kò rí ọ̀ọ́kán tàbí àwọn tí ó ń dá gbé apá ibìkan tí ó jìnà sí ìlú.

A gbà wí pé ẹ̀ka-èdè jẹ́ ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ kan pàtó tí ó jẹ́ ti àwọn ẹ̀yà kan tí wọ́n ń gbé ní agbègbè kan sí àwọn tí ó wà ní ìlú kan. Ṣùgbọ́n a kò fi ara mọ́ ọ̀rọ̀ bí ‘ará oko’, ‘àwọn tí kò rí ọ̀ọ́kán’ Ìdí ni pé àwọn tí ó ń sọ èdè àjùmọ̀lò (standard variety), ẹ̀ka-èdè náà ni àwọn onímọ̀ gbà pé wọ́n ń sọ. Olúmúyíwá (1994: 2) sọ pé ẹ̀ka-èdè jẹ́ ọ̀kan lára èdè àjùmọ̀lò àwọn ẹ̀yà kan tí okùn èdè so pọ̀. Awóbùlúyì (1981: 1) sọ pé ẹ̀ka-èdè jẹ́ ẹ̀yà-èdè kan tí wọ́n ń sọ ní àwùjọ kan tí irú àwùjọ ènìyàn bẹ́ẹ̀ gbọ́dọ̀ jẹ́ ara àwùjọ ńlá mìíràn tí èdè kan papọ̀.

Ẹ jẹ́ kí á di àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyìí mú – ‘ẹ̀dà-èdè’ àti ‘ẹ̀yà-èdè’. Adéníyì àti Òjó (2005: 25) ṣe àpèjúwe ẹ̀ka-èdè gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dà-èdè ńlá kan tàbí ọ̀nà ìbára-ẹni-sọ̀rọ̀ tí àwọn àdúgbò tàbí agbègbè kan ń ṣe àmúlò rẹ̀ láti fi gbé èrò ọkàn wọn jáde lọ́nà tí ó yàtọ̀ sí ti agbègbè mìíràn tí gbogbo wọn wà ní ẹ̀kùn kan náà, ṣùgbọ́n tí àwọn ará agbègbè méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ yìí gbọ́ ara wọn ní àgbọ́yé. Síwájú síi, ẹ̀dà-èdè ti àdúgbò kọ̀ọ̀kan ń sọ yìí ní àwọn àbùdá ètò ìró (fọnọ́lọ́jì), ìhun gírámà àti pípe ọ̀rọ̀ tí ó yàtọ̀ sí ti ẹ̀ka mìíràn. Àwọn òǹkọ̀wé yìí ṣe àlàyé pé: Èdè kédè tí àwọn tí ó ń sọ ọ́ bá pọ̀

díẹ̀, tí wọ́n sì takété sí ara wọn gbọ́dọ̀ ní ẹ̀ka, pàápàá jù lọ tí omi kíkún, igbó dídí tàbí òkè ńlá bá là wọ́n láàárín. Wàyìí ò, ẹ jẹ́ kí á ṣe àpèjúwe àlàyé yìí lórí àwòrán ẹ̀ka igi ìsàlẹ̀ yìí:




Àwòrán tí ó wà lókè yìí fi hàn pé èdè tí a ṣe àdàpè rẹ̀ bíi 'Y' ní ẹ̀ka mẹ́rin (1-4). Ẹ̀yà tàbí ẹ̀ka mẹ́rẹ̀ẹ̀rin pín láti ara èdè kan náà. Wọ́n sì fi ara jọ ara wọn lái ka àwọn ìyàtọ̀ díẹ̀díẹ̀ tí ó wà láàrin wọn. Ìyàtọ̀ yìí lè jẹ mọ́ ètò ìró, ìhun gírámà tàbí àwọn ọ̀rọ̀ kọ̀ọ̀kan tí ó yàtọ̀ sí ara wọn.

## 5.0 **Ìsọníṣókí**

Ní ìpín yìí, a ṣe àlàyé pé ẹ̀ka-èdè jẹ́ ẹ̀yà, ẹ̀dà, irú tàbí abala kan lára èdè fúnra rẹ̀. Èyí ni pé o jẹ́ ọ̀nà-ìbánisọ̀rọ̀ ti agbègbè kan lára àwọn ẹkùn tí èdè àjùmọ̀lò so pọ̀. Bí a ṣe ń sọ èdè Yorùbá yìí yàtọ̀ síra wọn ní agbègbè kọ̀ọ̀kan. Fún àpẹẹrẹ, Ọ̀yọ́, Ọ̀ṣun, Ifẹ̀, Èkìtì, Ìjẹ̀ṣà, Òǹdó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. A ó ṣe àlàyé kíkún lórí eléyìí nígbà tí a bá dé Módù Kejì àti Ìkẹta.

## 6.0 **Iṣẹ́ ṣíṣe**

(a) Kíni ẹ̀ka-èdè jẹ́?

(b) Dárúkọ àwọn agbègbè, ìlú, ìpínlẹ̀ àti orílẹ̀ èdè tí wọ́n ti ń sọ èdè Yorùbá.

## 7.0 **Ìwé ìtọ́kasí**

Adéníyì, H.R. àti Akinloyè Òjó (2005). *Ìlò èdè àti èdè Yorùbá.* African World Press, Inc.

Adétugbo, A. (1967). *The Yorùbá language in western Nigeria: its major dialect areas.* Ann Arbor, Michigan: University Microfilms International.

Adétugbo, A. (1982). Towards a Yorùbá dialectology, in Adébísí Afọláyan (ed). Yorùbá language and literature. Ibadan: University Press Limited and University of Ifẹ̀ Press, pp. 207-224.

Akínkùgbé, O.O. (1978). A comparative phonology of Yorùbá dialects; Iṣẹkiri and Igala. Ph.D. Thesis, Department of Linguistics, University of Ibadan, Unpublished.

Awóbùlúyì, O. (1988). *Àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá: Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Èdè Yorùbá ti Ọdún 1988*. Pastoral Institute, Bodija, Ibadan. November 24-26.

Fadoro, J.O. (2007). Dialectology. Ibadan Distance Learning Centre, Ibadan.

## MODÙ I: ÌPÍN KEJÌ

## ÌWÚLÒ Ẹ̀KA ÈDÈ

### 1.0 Ìfáàrà

Bí a bá yẹ àlàyé tí Chambers àti Trudgil tí a mẹ́nu bà ní ìsọ̀rí kìn-ín-ní iṣẹ́ yìí ní ojú ewé kẹta (3) a lè má a lérò pé ẹ̀ka-èdè kò wúlò. Ṣùgbọ́n a ti ṣe àlàyé pé oríkì tí àwọn òǹkọ̀wé Chambers àti Trudgil fún ẹ̀ka èdè kù díẹ̀ káàtó. Ẹ̀ka-èdè kìí ṣe ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ àwọn 'ará oko' 'ti kò rí ọ̀ọ̀kán, ó kàn jẹ́ ẹ̀ka-èdè tàbí ẹ̀yà/ẹ̀dà kan pàtó tí wọ́n ń sọ ní agbègbè kan ni.

### 2.0 Èròǹgbà àti afojúsùn

Kókó àlàyé tí a fẹ́ ṣe ní ìpín ẹ̀kọ́ yìí ni pé ẹ̀ka-èdè wúlò púpọ̀, ó sì le è ṣiṣẹ́ tí èdè àjùmọ̀lò (standard variety) fúnra rẹ̀ le è ṣe. A ní ìrètí wí pé akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè ṣe àlàyé kíkún lórí àwọn ìwúlò ẹ̀ka-èdè lẹ́yìn tí a bá parí ìpín ẹ̀kọ́ yìí.

### 3.0 Ìbéèrè ìṣàájú

Ǹjẹ́ o lérò pé ẹ̀ka-èdè wúlò rárá?

### 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Àwọn ọ̀nà tí èdè àjùmọ̀lò (language/standard variety) gbà wúlò ní ẹ̀ka-èdè fúnra rẹ̀ náà gbà wúlò. Ní àkọ̀kọ́, bí èdè fúnra rẹ̀ ṣe jẹ́ ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ ní ẹ̀ka-èdè náà jẹ́ ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ kan tí ó jẹ́ àrà ọ̀tọ̀.

Ṣáájú, bí a ṣe ń fi èdè gbé èrò ọkàn wa jáde, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni a ń fi ẹ̀ka-èdè gbé èrò ọkàn wa jáde (medium of expression). Ohunkóhun tí a bá lè rò l'ọ́kàn ni a lè fi ẹ̀ka-èdè gbé jáde lọ́nà tí ó yéni yéké.

Ìpolówó ọjà jẹ́ ọ̀kan gbòógì lára ìwúlò èdè, bẹ́ẹ̀ náà ni ẹ̀ka-èdè ṣe wúlò fún ìpolówó ọjà. Eléyìí wọ́pọ̀ púpọ̀ lórí ẹ̀rọ rédíò àti móhùn-máwòrán (television). Gẹ́gẹ́ bí a ti mọ̀ wí pé ìpolówó ọjà ni àgúnmu òwò, ẹ̀ka-èdè agbègbè kọ̀ọ̀kan wúlò fún ìpolówó ọjà ní ẹ̀kùn kọ̀ọ̀kan tí a ti ń sọ ọ́. (Advertisement).

A má a ń lo ẹ̀ka-èdè fún sísọ ọ̀rọ̀ àṣírí (secret conversation) tí a bá wà ní àárín ọ̀pọ̀ ènìyàn tí wọ́n ń sọ oríṣìíríṣìí ẹ̀ka-èdè tí ó pọ̀. Eléyìí wúlò ní àwùjọ tí a bá fura

(suspect) pé ọ̀tẹ̀, rìkíṣí àti tẹ̀mbẹ̀lẹ̀kun wọ́pọ̀ sí. Tí a bá fẹ́ láti sọ ọ́ lọ́nà tí gbogbo ènìyàn yóò gbọ́, a lè sọ èdè àjùmọ̀lò.

Ẹ̀ka-èdè wúlò púpọ̀ fún ìpanilẹ́rìn-ín (comedy). Eléyìí wúlò púpọ̀ nínú eré orí ìtàgé Yorùbá àti àwọn èdè mìíràn. Àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá kan wà tí wọ́n pani lẹ́rìn-ín púpọ̀. Fún àpẹẹrẹ, Ìjẹ̀bú, Ìjẹ̀ṣà, Èkìtì àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Èyí tí ó fara pẹ́ eléyìí ni lílo ẹ̀ka-èdè fún eré orí ìtàgé. Eléyìí jẹyọ nínú iṣẹ́ Bàbá Sàlá ní ayé ìgbà kan. Láyé òde òní, tí a bá wo àwọn eré orí ìtàgé tí Ọ̀gbẹ́ni Ọdúnladé Adékọ́lá àti Arákùnrin tí a ń pè ní Ìjẹ̀bú ti kópa, a ó rí i wí pé ọ̀pọ̀ ìgbà ni wọ́n má a ń lo ẹ̀ka-èdè Ìjẹ̀bú. Fún àpẹẹrẹ, ‘Sàámú Alájo.’

Ẹ̀ka-èdè tún wúlò púpọ̀ fún ìròyìn ẹsẹ̀ kùkú. Fún àpẹẹrẹ, lórí ẹ̀rọ móhùn-máwòrán ti ìpínlẹ̀ Ògùn, wọ́n má a ń sọ ẹ̀dà ìròyìn ní ẹ̀ka-èdè Ègùn. Eléyìí má a ń ṣẹlẹ̀ náà ní àwọn ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun (Ìjẹ̀ṣà) àti Ìpínlẹ̀ Èkìtì níbi tí wọ́n ti má a ń sọ ẹ̀dà ìròyìn ní ẹ̀ka-èdè Ìjẹ̀ṣà àti ẹ̀ka-èdè Èkìtì.

Ẹ̀ka-èdè tún wúlò fún ìsọmọlórúkọ. Fún àpẹẹrẹ, tí a bá gbọ́ àwọn orúkọ bí i Elúfisan, Elújọba abbl, a ó mọ̀ wí pé àwọn tí ó ń jẹ́ orúkọ bẹ́ẹ̀ ti Ilé-Ifẹ̀ wá. Àwọn Ìjẹ̀bú a má a sọ ọmọ ní Ṣóyínká, Ṣówándé, Ṣówọlé àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Bákan náà, ẹ̀ka-èdè wúlò fún iṣẹ́ ìwádìí ìjìnlẹ̀ lórí èdè. Fún àpèjúwe iṣẹ́ lórí i Àńkòò fáwẹ̀lì (vowel harmony), wọ́pọ̀ nínú àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá àárin gbùngbùn. A tún rí àwọn òǹkọ̀wé tí wọ́n má a ń kọ iṣẹ́ wọn ní ẹ̀ka-èdè. Fún àpẹẹrẹ, òǹkọ̀wé tí ó pe ara rẹ̀ ní Ṣóbò Aróbíodù. Bákan náà ni òǹkọ̀wé tí ó lo Kúnlé Ológundúdú.

Lákòótán, ẹ̀ka-èdè wúlò fún ìdánimọ̀ (identity). Ìdí ni èyí, tí ó fi jẹ́ pé tí a bá ti gbọ́ àwọn orúkọ kan, a lè sọ agbègbè tí ẹni tí ó ń jẹ́ orúkọ náà ti wá. Bẹ́ẹ̀ ni àwọn àgbà a má a wí pé: A má a ń fún ọmọ ní orúkọ torí ọjọ́ tí yóò bá dáràn.

Ẹ jẹ́ kí a wo ẹ̀ka èdè yìí fún ìrántí.

**Ìwúlò Ẹ̀ka Èdè**

- Ìbánisọ̀rọ̀.
- Ìdánimọ̀
- Ìpolowó Ọjà
- Síso Ọ̀rọ̀ Àṣírí
- Ìsọmọlórúkọ
- Ìpanilẹ́rìn-ín
- Kíkọ́ Àṣà
- Eré Orí Ìtàgé
- Eré Ìbílẹ̀
- Ìròyìn
- Èsẹ́ kùkù

## 5.0 **Ìsọníṣókí**

Àwọn ìwúlò ẹ̀ka-èdè tí a mẹ́nubà ní ìsọ̀rí yìí ni a pín sí ọ̀nà mẹ́wàá – ìbánisọ̀rọ̀/gbígbé èrò ọkàn jáde, ìpolówó ọjà, sísọ ọ̀rọ̀ àṣírí, ìpanilẹ́rìn-ín, eré orí ìtàgé, ìròyìn ẹ̀ṣẹ̀ kùkù, ìsọmọlórúkọ, iṣẹ́ ìwádìí ìjìnlẹ̀ lórí èdè, kíkọ́mọ ní àṣà/ìwà ọmọlúàbí/eré ìbílẹ̀ àti ìdánimọ̀. Eléyìí fi hàn kedere pé gẹ́gẹ́ bí èdè àjùmọ̀lò fúnra rẹ̀ ṣe wúlò náà ni àwọn ẹ̀ka-èdè wúlò jọjọ.

## 6.0 **Iṣẹ́ ṣíṣe**

Ṣe àlàyé kíkún lórí àwọn ọ̀nà tí ẹ̀ka-èdè gbà wúlò.

## 7.0 **Ìwé ìtọ́kasí**


Adéníyì, H.R. àti Akinloyè Òjó (2005). *Ìlò èdè àti èdè Yorùbá.* African World Press, Inc.

Adétugbo, A. (1967). *The Yorùbá language in western Nigeria: its major dialect areas.* Ann Arbor, Michigan: University Microfilms International.

Adétugbo, A. (1982). Towards a Yorùbá dialectology, in Adébísí Afọláyan (ed). Yorùbá language and literature. Ibadan: University Press Limited and University of Ifẹ̀ Press, pp. 207-224.

Akínkùgbé, O.O. (1978). A comparative phonology of Yorùbá dialects; Iṣẹkiri and Igala. Ph.D. Thesis, Department of Linguistics, University of Ibadan, Unpublished.

Awóbùlúyì, O. (1988). *Àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá: Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Èdè Yorùbá ti Ọdún 1988*. Pastoral Institute, Bodija, Ibadan. November 24-26.

Fadoro, J.O. (2007). Dialectology. Ibadan Distance Learning Centre, Ibadan.

## MÓDÙ I: ÌPÍN KẸTA
## PÌPẸ̀KA ÈDÈ

### 1.0 Ìfáàrà

Gẹ́gẹ́ bí àkàwé tí a ṣe ní ìpín kìn-ín-ní lááárín èdè, igi àti ọ̀nà tí wọ́n má a ń gbà pẹ̀ka, ìsọ̀rí yìí dá lórí ìtàn àtẹnudẹ́nu àti ìtàn àkọsílẹ̀ tí ó sọ pé gbogbo ọmọ Yorùbá lápapọ̀ jáde lára Odùduwà ní Ilé-Ifẹ̀. Tí èyí bá jẹ́ òtítọ́ pé ọmọ Odùduwà ni gbogbo Yorùbá ní àtètèkọ́ṣe, èyí túmọ̀ sí pé èdè àjùmọ̀lò kan náà ló so gbogbo wa papọ̀ ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ kó tó di pé ìpínyà bẹ̀rẹ̀ nígbà tí ó di pé àwọn Yorùbá ń pọ̀ sí i.

### 2.0. Èròǹgbà àti àfojúsùn

Ète wa ni láti ṣàlàyé kíkún lórí ìdí tí èdè fi má a ń pẹ̀ka ní ìsọ̀rí ẹ̀kọ́ yìí. Akẹ́kọ̀ọ́ ní láti le è sọ àwọn ìdí tí èdè fi má a ń pẹ̀ka lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí.

### 3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú

Ìlú wo ní àwọn ọmọ Yorùbá gbàgbọ́ pé wọ́n ti bẹ̀rẹ̀?

### 4.0 Idí tí àwọn ẹ̀ka-èdè fi ń yàtọ̀ sí ara wọn

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣáájú, ìtàn àtẹnudẹ́nu àti àkọsílẹ̀ fi yé wa pé ìlú Ilé-Ifẹ̀ ni gbogbo ọmọ Yorùbá ti ṣẹ̀ wá, a ní láti ṣe àgbéyẹ̀wò ìdí tí èdè Yorùbá fi wá pẹ̀ka sí oríṣìíríṣìí ọ̀nà.

Àkọsílẹ̀ fi yé wa pé nígbà tí ó di wí pé àwọn ìran Odùduwà bẹ̀rẹ̀ sí ní í pọ̀ sí i, tí wọ́n sì ń fọ́n káàkiri sí ìtòsí àti ọ̀nà jínjìn, bẹ́ẹ̀ náà ni ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ wọn bẹ̀rẹ̀ sí ní í yàtọ̀ sí ara wọn díẹ̀ díẹ̀. Ohun tí a ń sọ ni pé nígbà tí àwọn ọmọ Yorùbá bẹ̀rẹ̀ sí ní í gbèèrú sí i, wọn kò le è dúró sí ojú kan nítorí pé ojú kan kò le è gbà wọ́n mọ́, wọ́n ní láti má a fọ́n káàkiri. Èyí ni àwọn Òyìnbó ń pè ní ‘population explosion and expansion’.

A rí i pé nígbà tí ó di pé eléyìí ń ṣẹlẹ̀, ogun abẹ́lé bẹ̀rẹ̀ sí ní í wáyé, ogun òkèèrè náà bẹ̀rẹ̀ sí ní í jẹ yọ. Eléyìí bẹ̀rẹ̀ sí ní í fa ìgbòkègbodò àti ìfọ́nkáàkiri.

Nígbà tí èdè àìyedè, ogun àti ọ̀tẹ̀ wọlé, ó di wí pé kí àwọn tí a kó ní ìkogun má a di ẹrú fún àwọn tí ó ṣẹ́gun wọn. Eléyìí wá ń fa òwò-ẹrú ṣíṣe (slave trade). Bí a

bá wo àwọn orílẹ̀ èdè tí ó wà lẹ́yìn odi Nàìjíríà bí i Tógo, Benin Republic, Sierra Leone, Gambia, Cuba, Brazil àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, a ó rí wí pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ wọn ní wọ́n tà ní ẹrú sí àwọn orílẹ̀-èdè yìí. Kí ni ìtumọ̀ èyí? Bí àwọn náà ṣe ń bímọ, tí wọ́n ń gbèèrú sí i ni ẹ̀ka-èdè bẹ̀rẹ̀ sí ní í jẹyọ lóríṣìíríṣìí.

Ìṣípòpadà tàbí gbígbéra lọ láti agbègbè kan lọ sí ibòmíràn náà ń fa kí ẹ̀ka-èdè má a yàtọ̀ sí ara wọn.

Ohun mìíràn ni òwò-ṣíṣe pẹ̀lú àwọn tí èdè tàbí ẹ̀ka-èdè wọn yàtọ̀ síra. Eléyìí má a ń fa bí àwọn ẹ̀ka-èdè ṣe bẹ̀rẹ̀ sí ní í yàtọ̀ sí ara wọn. Báwo ni èyí ṣe máa ń wáyé? Nígbàtí àwọn oníṣòwò àti oníbààrà bá bẹ̀rẹ̀ síí dínàá-dúrà, tí wọ́n sì ń kọ́ èdè araa wọn, ìyàtọ̀ díẹ̀ díẹ̀ má abá èdè abínibí wọn.

Ìgbéyàwó láàárín àwọn tí ó ti agbègbè mìíràn, tí ẹ̀ka-èdè tí wọ́n ń sọ sí, yàtọ̀ sí ara wọn, a má a ń fa kí oríṣìíríṣìí ẹ̀ka-èdè má a jẹ yọ. Fún àpẹẹrẹ, tí Ọ̀yọ́ àti Èkìtì bá fẹ́ ara wọn gẹ́gẹ́ bí lọ́kọ-láya, lẹ́yìn ọ̀pọ̀ ọdún tí wọ́n ti ń gbé pọ̀, tí wọ́n sì ń bímọ, ẹ̀ka èdè wọn a bẹ̀rẹ̀ sí níí yàtọ̀ díẹ̀díẹ̀. Eléyìí á mú ìyàtọ̀ wáyé nínú ìsọ̀rọ̀ àwọn ọmọ lẹ́yìn ọjọ́ pípẹ́.

Bí àjàkálẹ̀ àrùn bá bẹ́ sílẹ̀, tí ó wá di wí pé àwọn ènìyàn ń sá kúró láti agbègbè kan sí ibòmíràn, èdè má a ń ti ipasẹ̀ eléyìí pín sí ẹ̀ka oríṣìíríṣìí.

Bákan náà, ìbáṣepọ̀ láàárín ẹ̀yà kan àti òmíràn má a ń fa kí ẹ̀ka-èdè bẹ̀rẹ̀ sí ní í yàtọ̀ sí ara wọn.

Igbó dídí, omi kíkún àti àwọn òkè ńlá tí ó pín àwọn àwùjọ tí wọ́n ń sọ èdè kan náà níyà a má a mú kí ìyípadà de bá bí àwọn ènìyàn wọ̀nyìí ṣe ń sọ èdè wọn. Àwọn nǹkan mẹ́ta wọ̀nyìí wọ́pọ̀ nínú ìdí tí ẹ̀ka-èdè fi má a ń wáyé.

Lákòótán, ìfẹ́ lati mọ àwọn ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ láàárín àwọn ẹ̀yà mìíràn tí ó mú kí a súnmọ́ wọn sí i a má a fa ìyàtọ̀ láàrin àwọn ẹ̀ka-èdè.

## 4.0 Ìsọníṣókí

A ti ménu ba àwọn èrèdìí bí i mọ́kànlá tí àwọn èdè fi má a ń pẹ̀ka nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. Àwọn ohun tí a ménubà ní pàtó ni – gbígbèèrú sí i tí ó fa ìfọ́nká, èdè àìyedè tí ó fa ogun abẹ́lé, òwò ẹrú, ìṣípòpadà, òwò ṣíṣe, ìgbéyàwó, àjàkálẹ̀ àrùn,

ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú ẹ̀yà mìíràn, omi kíkún, òkè ńlá, igbó dídí àti ìfé láti mọ ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ káàkiri.

## 5.0 **Iṣẹ́ ṣíṣe**

Ṣe àlàyé kíkún lórí ọ̀nà tí èdè fi má a ń pẹ̀ka.

## 6.0 **Ìwé ìtọ́kasí**


Adéníyì, H.R. àti Akinloyè Òjó (2005). *Ìlò èdè àti èdè Yorùbá.* African World Press, Inc.

Adétugbo, A. (1967). *The Yorùbá language in western Nigeria: its major dialect areas.* Ann Arbor, Michigan: University Microfilms International.

Adétugbo, A. (1982). Towards a Yorùbá dialectology, in Adébísí Afọláyan (ed). Yorùbá language and literature. Ibadan: University Press Limited and University of Ifẹ̀ Press, pp. 207-224.

Akínkùgbé, O.O. (1978). A comparative phonology of Yorùbá dialects; Iṣẹ̀kiri and Igala. Ph.D. Thesis, Department of Linguistics, University of Ibadan, Unpublished.

Awóbùlúyì, O. (1988). *Àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá: Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Èdè Yorùbá ti Ọdún 1988.* Pastoral Institute, Bodija, Ibadan. November 24-26.

Fadoro, J.O. (2007). Dialectology. Ibadan Distance Learning Centre, Ibadan.

## MÓDÙ I: ÌPÍN KẸRIN

## ÀLÈÉBÙ TÍ Ó WÀ NÍNÚ TÍTẸRAMỌ́ ẸKA-ÈDÈ SÍSỌ

1. **Ìfáàrà**

A ti ṣe àlàyé ní módù kẹta pé àwọn ẹ̀ka-èdè wúlò púpọ̀ gẹ́gẹ́ bí èdè àjùmọ̀lò fúnra rẹ̀ ṣe wúlò. Síbẹ̀, a ní láti fi yé wa pé títẹramọ́ ẹ̀ka-èdè sísọ tún ní àwọn àléébù tirẹ̀. Eléyìí ni ohun tí ó jẹ wá lógún ní ìpìn yìí.

2. **Èròǹgbà àti àfojúsùn**

Kókó àlàyé tí a fẹ́ ṣe ní abẹ́ ìsọ̀rí yìí dá lórí àléébù tí títẹra mọ́ ẹ̀ka-èdè sísọ lè mú lọ́wọ́. Akẹ́kọ̀ọ́ yóò le ṣe àlàyé lórí àwọn àléébù tàbí wàhálà tí ó rọ̀ mọ́ kíá jingíri nínú sísọ ẹ̀ka-èdè lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí.

3. **Ìbéèrè ìṣàájú**

Ǹ jẹ́ o lérò pé àlèébù wà nínú títẹramọ́ ẹ̀ka-èdè sísọ?

4.0 **Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

1. **Ìpín kìn-ín-ní**

Àwọn kókó tí a ó mẹ́nu bà.

1. Àsáwọ̀/ìtasí fún èdè àkọ́kúnténi lẹ́yìn èdè ẹni/abínibí (interference 1st/2nd language)
2. Ẹlẹ́yàmẹ̀yà (Ethnicity)
3. Ìrẹ́jẹ (cheating)
4. Ìfàsẹ́yìn (Retrogression)
5. Ogun abẹ́lé (Civil war)

**Àlàyé**

Àwọn onímọ̀ ti fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé lọ́pọ̀ ìgbà, tírẹramọ́ ẹ̀ka-èdè sísọ jù má a ń ṣe àkóbá tàbí ìpalára fún kíkọ èdè mìíràn lẹ́yìn tí a ti lè sọ èdè abínibí dáradára. Lákọ̀ọ́kọ́, ẹ̀ka-èdè tí a jingíri nínú rẹ̀ fi àwọn àbùdá kan yàtọ̀ sí èdè àjùmọ̀lò. Fún àpẹẹrẹ, nínú Yorùbá àjùmọ̀lò, ìró /ʃ/ má a ń jẹ yọ nínú àwọn àpẹẹrẹ yìí: /iʃẹ́/ (job) ɛʃɛ (sin) [ɛʃ̃ì] (religion), [ʃe] (do), [ʃí] (open) abbl. Nínú ẹ̀ka-èdè Ìbàdàn, Ìjẹ̀ṣà, Ifẹ̀,

Èkìtì, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, ìró /ʃ/ kò fara hàn. Àwọn tí ó ń sọ àwọn ẹ̀ka-èdè wọ̀nyìí a má a lo /s/ dípò /ʃ/, eléyìí kò bójúmu. Irú rẹ̀ má a ń pa èdè Òyìnbó kíkọ lára. Fún àpẹẹrẹ, tí a bá fẹ́ láti pe àwọn ọ̀rọ̀ bí i: shape, shop, shoe, show abbl.

Tí àwọn ẹ̀yà tí ẹ̀ka-èdè papọ̀ bá kó ara wọn jọ, tí wọ́n sì dé ipò àṣẹ láti jẹ gàba lórí àwọn ẹ̀yà mìíràn tí ẹ̀ka-èdè ti wọ́n yàtọ̀ sí ti àwọn tí ó wà ní ipò àṣẹ, ìkùnsínú á wà.

Ìkùnsínú a ṣe okùnfà fún ẹlẹ́yàmẹ̀yà. Tí àwọn àwùjọ yìí kò bá fi ẹnu eléyìí jóná ní kíá mọ́sá, a ṣe okùnfà fún ìrẹ́jẹ àti ìfàsẹ́yìn. Àwọn àgbà òǹkọ̀wé sọ fún wa pé eléyìí wáyé láàárín Ifẹ̀ àti Modákẹ́kẹ́ nígbà tí ogun abẹ́lé bẹ́ sílẹ̀. A tún rí i kà nínú Bíbélì pé irú ìṣẹ̀lẹ̀ yìí ṣẹlẹ̀ láàárín àwọn ẹ̀yà Ísráẹ́lì (Ephraim and Gilead). Ìwé Onídàájọ́ (Judges 12: 5-6), níbi tí àwọn ọmọ Gileadi ti di ọ̀nà Jọ́dáánì mọ́ àwọn ará Éfréémù. Tí ẹnikẹ́ni bá ti fẹ́ kọjá, wọ́n a sọ pé kí ó pe ọ̀rọ̀ kan ‘shiboleth’ tí ó túmọ̀ sí ‘odò ṣíṣàn’ tàbí ‘hóró ọkà’. Ẹnikẹ́ni tí ó bá pe ‘siboleth’ dípò ‘shiboleth’, wọn a dá a mọ̀ pé ará Éfréémù ni, wọn a sì ṣe ikú pa ẹni bẹ́ẹ̀.

Bí a bá mú eléyìí lò, a ó rí i pé ogun abẹ́lé (civil war) lè tipa ẹlẹ́yà-mẹ̀yà àti fífá apá orí kan dá apá kejì sí wáyé.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Kókó àwọn ohun tí a ṣe àlàyé rẹ̀ ní abala yìí ni pé: Tí a bá jingíri ní sísọ ẹ̀ka-èdè, àwọn wàhálà bí i àkóbá fún èdè tí a bá tún fẹ́ kọ lẹ́yìn èdè abínibí, (second language) ìrẹ́jẹ, ìkùnsínú, ojúṣàájú, ẹlẹ́yàmẹ̀yà, ogun abẹ́lé àti ìfàsẹ́yìn lè wáyé tí a kò bá kíyèsára.

## 6.0 Iṣẹ́ ṣíṣe

(a) Sọ kókó márùn-ún nínú àwọn àlèébù tí ó lè wáyé láti ara títẹramọ́ ẹ̀ka-èdè sísọ.

(b) Ṣe àlàyé mẹ́rin nínú wọn.

## 7.0 **Ìwé ìtọ́kasí**


Adéníyì, H.R. àti Akinloyè Òjó (2005). *Ìlò èdè àti èdè Yorùbá.* African World Press, Inc.

Adétugbo, A. (1967). *The Yorùbá language in western Nigeria: its major dialect areas.* Ann Arbor, Michigan: University Microfilms International.

Adétugbo, A. (1982). Towards a Yorùbá dialectology, in Adébísí Afọláyan (ed). Yorùbá language and literature. Ibadan: University Press Limited and University of Ifẹ̀ Press, pp. 207-224.

Akínkùgbé, O.O. (1978). A comparative phonology of Yorùbá dialects; Iṣẹkiri and Igala. Ph.D. Thesis, Department of Linguistics, University of Ibadan, Unpublished.

Awóbùlúyì, O. (1988). *Àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá: Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Èdè Yorùbá ti Ọdún 1988*. Pastoral Institute, Bodija, Ibadan. November 24-26.

Fadoro, J.O. (2007). Dialectology. Ibadan Distance Learning Centre, Ibadan.

## MÓDÙ I: ÌPÍN KARÙN-ÚN

## Ọ̀RỌ̀ AÌTỌ́ NÍPA Ẹ̀KA ÈDÈ (STEREOTYPES)

### 1.0 Ìfáàrà

Àwọn ọ̀rọ̀ àìtọ́ kan wà tí àwọn ènìyàn máa ń sọ nípa ẹ̀ka èdè tí ó wọ́pọ̀ láàrin àwọn tí kò mọ ohun tí ẹ̀ka èdè jẹ́ àti ìwúlò rẹ̀ ní àwùjọ kọ̀ọ̀kan. Eléyìí ni ó jẹ wá lógún ní ìpín tí a wà yìí.

### 2.0 Èròǹgbà àti Àfojùsùn

Gẹ́gẹ́ bí a ti yàn-an nínú ìfáàrà, èròǹgbà wa ni láti ṣe àlàyé àwọn ọ̀rọ̀ àìtọ́ kan tí àwọn tí kò ní ìmọ̀ kíkún nípa ohun ẹ̀ka èdè jẹ́. Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ á lè ṣàlàyé àwọn ọ̀rọ̀ kòtọ́ wọ̀nyìí ní kíkún.

### 3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú

Àwọn wo ni ó máa ń sọ àwọn ọ̀rọ̀ àìtọ́ nípa ẹ̀ka èdè?

### 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Ọ̀kan nínú àwọn ọ̀rọ̀ kòtọ́ tí àwọn kan máa ń sọ nípa ẹ̀ka-èdè ni pé, ẹ̀ka-èdè jẹ́ ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ àwọn ará oko, tí wọ́n dá wà ní ibì kan, tí wọn kò sì ní ìmọ̀ nípa ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ ní ibòmíràn, èyí ni pé ó jẹ́ ìpèdè àwọn tí kò rọ́ọ̀ọ̀kán. Eléyìí kò rí bẹ́ẹ̀ rárá. Ohun tí àwọn onímọ̀ fẹnu kò sí ni pé kò sí ohun tí ó jọ bẹ́ẹ̀. Gbogbo èdè ni ó ní ẹ̀ka àti wí pé gbogbo ènìyàn – yálà ní ìlú ńlá tàbí ìlú kéékèèké ni ó ń sọ ẹ̀ka èdè kan tàbí òmíràn.

Àwọn kan máa ń sọ pé ẹ̀ka èdè jẹ́ èdè àwọn ènìyàn tí kò já mọ́ nǹkan, tí wọn kò ní ipò, tí wọn kò sì kàwé tàbí àwọn èrò ẹ̀yìn. Eléyìí kò rí bẹ́ẹ̀ rárá. Gbogbo ènìyàn ni ó ń sọ ẹ̀ka èdè láì ka ipò wọn sí – olówó, mẹ̀kúnnù, ẹni tí ó kàwé tàbí ẹni tí kò kàwé. Èdè àjùmọ̀lò (Standard Variety) fúnra rẹ̀ gan an jẹ́ ẹ̀ka èdè kan.

Àwọn mìíràn á sọ pé ẹ̀ka èdè jẹ́ èyí tí ó wà fún àwọn ènìyàn péréte tí kò pọ̀, tí wọn kò sì lajú. Eléyìí náà kò rí bẹ́ẹ̀. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ẹ̀ka èdè ni ó ní ọ̀kẹ́ àìmọye àwọn tí ó ń sọ wọn. Fún àpẹẹrẹ, tí a bá wo àwọn ẹ̀ka èdè Yorùbá bí i Ọ̀yọ́, Oǹdó,

Ìjẹ̀ṣà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, ọ̀pọ̀ mílíọ̀nù ènìyàn ni ó ń sọ ìkọ̀ọ̀kan wọn ní àwọn ìlú ńlá bí i Ọ̀yọ́ Aláàfin, Oǹdó, Iléṣà àti bẹ́ẹ̀ béẹ̀ lọ.

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe ṣàlàyé ní ìpín àkọ́kọ́ módù yìí, Chambers àti Trudgil (1994: 3) ni ó fún ẹ̀ka èdè ní oríkì tí ó kù díẹ̀ káàtó pé "ẹ̀ka èdè ni ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tí àwọn ará oko, àwọn tí kò rọ́ọ̀ọ̀kán, tàbí àwọn tí ó kàn ń dá gbé apá ibìkan, tí ó jìnà sí ìlú." Eléyìí kò rí béẹ̀ rárá. Ohun tí àwọn onímọ̀ nípa èdè fi ẹnu kò lé lórí ni pé ẹ̀ka èdè kan fi àwọn ìyàtọ̀ tí ó wà nínú ìpín èdè kọ̀ọ̀kan nípa àbùdá fonọ́lọ́jì, ìhun gírámà àti pípe ọ̀rọ̀ jáde hàn ni. Eléyìí kò ní nǹkan ṣe nípa ènìyàn tí ó ń sọ ọ́, yálà ipò wọn, ibi tí wọ́n ń gbé tàbí bí wọ́n ṣe pọ̀ tó.

**Ọ̀rọ̀ Àìtọ́ Nípa Ẹ̀ka Èdè**

- Èdè àwọn ará oko
- Èdè àwọn tí Kò rọ́ọ̀ọ̀kán
- Ọ̀nà ìsọ̀rọ̀ àwọn òpè
- Ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ àwọn tí kò jámọ́ nǹkan
- Àwọn èdè tí àwọn tí ó ń sọ ọ́ kéré púpọ̀

## 5.0 Ìsọníṣókí

Ní ìsọ̀rí yìí, a ti ṣe àlàyé kíkún lórí àwọn ọ̀rọ̀ kòtọ́ tí àwọn tí àwọn kan máa ń sọ nípa ẹ̀ka èdè. Irú àwọn bẹ́ẹ̀ máa ń fi ojú tẹmbẹ́lú ẹ̀ka èdè gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà èdè tí àwọn ènìyàn péréte, tí wọ́n jẹ́ ará oko, tí kò lajú, tí kò sì rọ́wọ́ mú ń sọ. A ti fi yé wa pé eléyìí kò rí bẹ́ẹ̀ rárá.

## 6.0 Iṣẹ́ ṣíṣe

(a) Ṣe àlàyé kíkún lórí àwọn ọ̀rọ̀ kòtọ́ tí àwọn kan máa ń sọ nípa ẹ̀ka èdè.

(b) Kí ni o lè sọ nípa àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyìí?

## 7.0 Ìwé ìtọ́kasí

Adéníyì, H.R. àti Akinloyè Òjó (2005). *Ìlò èdè àti èdè Yorùbá.* African World Press, Inc.

Adétugbo, A. (1967). *The Yorùbá language in western Nigeria: its major dialect areas.* Ann Arbor, Michigan: University Microfilms International.

Adétugbo, A. (1982). Towards a Yorùbá dialectology, in Adébísí Afọláyan (ed). Yorùbá language and literature. Ibadan: University Press Limited and University of Ifẹ̀ Press, pp. 207-224.

Akínkùgbé, O.O. (1978). A comparative phonology of Yorùbá dialects; Iṣẹkiri and Igala. Ph.D. Thesis, Department of Linguistics, University of Ibadan, Unpublished.

Awóbùlúyì, O. (1988). *Àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá: Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Èdè Yorùbá ti Ọdún 1988*. Pastoral Institute, Bodija, Ibadan. November 24-26.

Fadoro, J.O. (2007). Dialectology. Ibadan Distance Learning Centre, Ibadan.

## MÓDÙ II: IṢẸ́ LÓRÍ Ẹ̀KA-ÈDÈ YORÙBÁ

Ní módù yìí, ìpín márùn-ún ni a ní gẹ́gẹ́ bí àlàyé tí a fihàn nínú àkòónú kọ́ọ̀sì yìí ní ojú ewé (iii). A ṣe àtúpalẹ̀ iṣẹ́ àwọn òǹkọ̀wé márùn-ún tí wọ́n ti ṣiṣẹ́ kíkún lórí ẹ̀ka èdè Yorùbá: Adétugbọ̀ (1967 (ii) Oyèlaran (1976) (iii) Akínkùgbé (1978) (iv) Awóbùlúyì (1998) (vi) Adéníyì àti Òjó (2005). Ẹ jẹ́ kí a tẹ̀síwájú.

### ÌPÍN KÌN-ÍN-NÍ
### IṢẸ́ ADÉTUGBỌ̀ (1967)

### 1.0 Ìfáàrà

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a gbọ́ pé àwọn òǹkọ̀wé kan ti ṣiṣẹ́ lórí ẹ̀ka-èdè Yorùbá ṣáájú ọdún 1967, nígbà tí iṣẹ́ òǹkọ̀wé Abíọ́dún Adétugbọ̀ jáde, a ò ní àkọsílẹ̀ tí ó dángájíá lórí eléyìí. Nítorí náà, iṣẹ́ Adétugbọ̀ ni èyí tí àkọsílẹ̀ rẹ̀ hàn kedere. Eléyìí ni a dojú kọ ní ìpín àkọ́kọ́ módù yìí.

### 2.0 Èròǹgbà àti àfojúsùn

Ète wa ní ìsọ̀rí yìí ni láti gbé iṣẹ́ Adétugbọ̀ (1967) tí ó pín ẹ̀ka èdè Yorùbá sí ọ̀nà mẹ́ta yẹ̀wò ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́. Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè ṣe àlàyé kíkún lórí ọ̀nà mẹ́ta tí Adétugbọ̀ pín ẹ̀ka èdè Yorùbá sí nínú iṣẹ́ rẹ̀ (1967).

### 3.0 Ìbéèrè ìṣàájú

Ẹ̀ka-èdè mélòó ni òǹkọ̀wé Adétugbọ̀ pín Yorùbá sí?

### 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Ṣáájú ohun gbogbo, ẹ jẹ́ kí a wo àwòrán ẹ̀ka èdè Yorùbá lórí ẹ̀ka igi (tree diagram) ìsàlẹ̀ yìí láti fi ọ̀nà mẹ́ta tí òǹkọ̀wé Adétugbọ̀ pín èdè Yorùbá sí.

**Adétugbọ̀ (1967)**




**Àlàyé lórí iṣẹ́ Adétugbọ́**

Ẹ jẹ́ kí á ṣe àlàyé lórí ẹ̀ka-èdè tí Adétugbọ́ pín, èyí tí a fi sí òkè ojú ewé yìí ní ṣókí. Òǹkọ̀wé Adétugbọ́ pín ẹ̀ka-èdè Yorùbá sí mẹ́ta – (a) Gúsù Ìlà Oòrùn (b) Ààrin Gbùngbùn (d) Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn. Lábẹ́ ẹ̀ka-èdè Gúsù Ìlà Oòrùn ni a ti rí Rẹ́mọ, Ìjẹ̀bú, Ẹ̀pẹ́, Oǹdó, Ìkálẹ̀, Ọ̀wọ̀ àti Ìlàjẹ. Àwọn ìpínlẹ̀ mẹ́ta ni a lè pín ẹ̀ka-èdè yìí sí – Ògùn, Èkó àti Oǹdó.

Ẹ̀ka kejì iṣẹ́ Adétugbọ́ ni Ààrin Gbùngbùn. Àwọn wọ̀nyìí ni Ifẹ̀, Ìjẹ̀ṣà, Àkúrẹ́ àti Èkìtì. Àwọn ìpínlẹ̀ mẹ́ta tí ó wà ní ìsọ̀rí yìí ni: Ọ̀ṣun, Oǹdó àti Èkìtì.

Ẹ̀ka tí ó gbẹ̀yìn ni Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn tí wọ́n ń sọ ní Ọ̀yọ́, Ṣakí, Ògbómọ̀ṣọ́, Ẹ̀gbá, Ẹ̀gbádò (Yewa) àti Ọ̀ṣun, tí wọ́n wà ní ìpínlẹ̀ Ògùn, Ọ̀yọ́ àti Ọ̀ṣun.

## 5.0 Ìsọníṣókí

A ti ṣe àlàyé lórí àwọn ẹ̀ka-èdè mẹ́ta tí òǹkọ̀wé Adétugbọ́ pín Yorùbá sí ní ìsọ̀rí yìí. Àwọn ẹ̀ka-èdè mẹ́ta náà ni Gúsù Ìlà Oòrùn, Ààrin Gbùngbùn àti Àríwá Iwọ̀ Oòrùn. A ti dárúkọ àwọn ọmọ abẹ́ ẹ̀ka kọ̀ọ̀kan, a sì tún ti sọ àwọ́n ìpínlẹ̀ tí a ti ń sọ àwọn ẹ̀ka-èdè yìí ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà. Ẹ jẹ́ kí a kíyèsíi pé òǹkọ̀wé Adétugbọ́ ṣe àlàyé pé nínú ẹ̀ka-èdè mẹ́tẹ̀ẹ̀ta, Àríwá Iwọ̀ Oòrùn ni ó súnmọ́ Yorùbá àjùmọ̀lò jùlọ.

## 6.0 Iṣẹ́ ṣíṣe

Ṣe àlàyé kíkún lórí ọ̀nà mẹ́ta tí Adétugbọ́ pín ẹ̀ka-èdè Yorùbá sí.

8.0 **Ìwé ìtọ́kasí**


Adéníyì, H.R. àti Akinloyè Òjó (2005). *Ìlò èdè àti èdè Yorùbá.* African World Press, Inc.

Adétugbo, A. (1967). *The Yorùbá language in western Nigeria: its major dialect areas.* Ann Arbor, Michigan: University Microfilms International.

Adétugbo, A. (1982). Towards a Yorùbá dialectology, in Adébísí Afọláyan (ed). Yorùbá language and literature. Ibadan: University Press Limited and University of Ifẹ̀ Press, pp. 207-224.

Akínkùgbé, O.O. (1978). A comparative phonology of Yorùbá dialects; Iṣẹkiri and Igala. Ph.D. Thesis, Department of Linguistics, University of Ibadan, Unpublished.

Awóbùlúyì, O. (1988). *Àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá: Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Èdè Yorùbá ti Ọdún 1988.* Pastoral Institute, Bodija, Ibadan. November 24-26.

Fadoro, J.O. (2007). Dialectology. Ibadan Distance Learning Centre, Ibadan.

## MÓDÙ II: ÌPÍN KEJÌ

## IṢẸ́ OYÈLÁRAN (1976)

### 1.0 Ìfáàrà

Òǹkọ̀wé Oyèláran pín èdè Yorùbá sí ẹ̀ka-èdè mẹ́rin. Ẹ jẹ́ kí á gbé eléyìí yẹ̀wò ní abẹ́ igi ẹ̀ka-èdè tí ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí.

**Oyèlaran (1976)**

Yorùbá

Ìwọ̀ Oòrùn (Western) → **1**

(ia) Ọ̀yọ́, Ìbàdàn, Ẹ̀gbá, Ọhọri, Ifọhin.
(b) Òkè Ògùn
(iia) Ṣakí, Ìjíó
(b) Kàbá, Sábẹẹ

(iii) (a) Benin & Togo
(b) Ifẹ̀ (Togo), Idiasa, Manigiri

**Àkíyèsí**:
(iib) & (iii) a & b
Àwọn Yorùbá tí a ń sọ lẹ́yìn odi Nàìjíríà.

1a, b, àti iia (Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ àti Ògùn

Gúsù Ìlà Oòrùn (South Eastern) → **2**

- Oǹdó, Ọ̀wọ̀
- Ìkálẹ̀ àti Ìlajẹ
- Ìjẹ̀bú

Ìpínlẹ̀: Oǹdó àti Ògùn

Ààrin Gbùngbùn (Central) → **3**

Ààrin Gbùngbùn
Ifẹ̀, Ìjẹ̀ṣà, Èkìtì
↓
Ìpínlẹ̀
↓
Ọ̀yọ́, Èkìtì

Àríwá Ìlà Oòrùn (North Eastern) → **4**

Aríwá, Ilà Oòrùn
1. Ìgbómìnà, Kàkàǹdá, Ìgbọ̀lọ̀
2. Jùmú, Bùnú́, Ọ̀wọ̀rọ̀, Owé & Ẹ̀gbẹ̀
3. Ìpínlẹ̀: Ọ̀yọ́, Kwara àti Kogí

## 2.0 Èròǹgbà àti àfojúsùn

Ète wa ní ìsọ̀rí yìí ni láti gbé àwọn ẹ̀ka-èdè mẹ́rin tí òǹkọ̀wé Oyèláràn pín èdè Yorùbá sí yẹ̀wò. Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ á lè ṣe àlàyé kíkún lórí iṣẹ́ òǹkọ̀wé náà.

## 3.0 Ìbéèrè ìṣàájú

Ọ̀nà mélòó ni Oyèláran pín ẹ̀ka-èdè Yorùbá sí nínú iṣẹ́ rẹ̀ 1976?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Òǹkọ̀wé Oyèláran (1976) pín èdè Yorùbá sí ẹ̀ka-èdè mẹ́rin ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Àwọn wọ̀nyìí ni: (a) Yorùbá Ìwọ̀ Oòrùn (b) Yorùbá Gúsù Ilà Oògùn (d) Yorùbá Àárin Gbùngbùn (e) Yorùbá Àríwá Ilà Oòrùn.

Lẹ́bẹ́ ẹ̀ka Yorùbá Ìwọ̀ Oòrùn ni a ti rí Ọ̀yọ́, Ìbàdàn, Ẹ̀gbá, Ọ̀họ̀rì, Ìfọ̀hìn, Òkè-Ògùn, Ṣakí, Ìjíó, Kétu, Sábẹ̀ẹ́ àti Ọ̀ṣun. A rí àwọn ẹ̀ka-èdè wọ̀nyìí ní Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́, Ògùn, Ọ̀ṣun àti Kwárà. Kétu àti Sabẹ́ẹ̀ tún wà ní ẹ̀yìn odi Nàìjíríà (Republic of Benin). Òǹkọ̀wé Oyèláran sọ wí pé ẹ̀ka-èdè yìí ni ó súnmọ́ Yorùbá àjùmọ̀lò jùlọ.

Ìpín kejì ni Gúsù Ìlà Oògùn. Àwọn wọ̀nyìí ni Oǹdó, Ọ̀wọ̀, Ìkálẹ̀, Ìlàjẹ àti Ìjẹ̀bú tí a ń sọ ní ìpínlẹ̀ Oǹdó àti Ògùn.

Ìpín kẹta ni Yorùbá Àárin Gbùngbùn níbi tí a gbé rí Ifẹ̀, Ìjẹ̀ṣà, Àkúrẹ́ àti Èkìtì tí wọ́n ń sọ ní Ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun, Oǹdó àti Èkìtì.

Ìpín tí ó gbẹ̀yìn ní abala yìí ni Àríwá Ilà Oòrùn lábẹ́ èyí tí a ti rí Ìgbómìnà, Kàkàǹdá, Ìgbọ̀lọ̀, Ìjùmù, Ọ̀wọ̀rọ̀, Owé, Yàgbà àti Ègbẹ tí a ń sọ ní Ìpínlẹ̀ Kwárà àti Kogí.

## 5.0 Ìsọníṣókí

A ṣe àlàyé lórí iṣẹ́ Oyèláran (1976) ní ìsọ̀rí yìí. Òǹkọ̀wé yìí pín èdè Yorùbá sí ẹ̀ka-èdè mẹ́rin, èyí ni: Ìwọ̀ Oòrùn, Gúsù Ìlà Oòrùn, Àárin Gbùngbùn àti Àríwá Ilà Oòrùn. A ti dárúkọ àwọn ìpínlẹ̀ tí àwọn ẹ̀ka-èdè yìí wà káàkiri orílẹ̀ èdè Nàìjíríà àti lẹ́yìn odi.

6.0 **Iṣẹ́ ṣíṣe**

(a) Dárúkọ ọ̀nà mẹ́rin tí òǹkọ̀wé Oyèláran pín èdè Yorùbá sí.

(b) Ṣe àlàyé kíkún lórí wọn.

7.0 **Ìwé Ìtọ́kasí**


Adéníyì, H.R. àti Akinloyè Òjó (2005). *Ìlò èdè àti èdè Yorùbá.* African World Press, Inc.

Adétugbo, A. (1967). *The Yorùbá language in western Nigeria: its major dialect areas.* Ann Arbor, Michigan: University Microfilms International.

Adétugbo, A. (1982). Towards a Yorùbá dialectology, in Adébísí Afọláyan (ed). Yorùbá language and literature. Ibadan: University Press Limited and University of Ifẹ̀ Press, pp. 207-224.

Akínkùgbé, O.O. (1978). A comparative phonology of Yorùbá dialects; Iṣẹkiri and Igala. Ph.D. Thesis, Department of Linguistics, University of Ibadan, Unpublished.

Awóbùlúyì, O. (1988). *Àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá: Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Èdè Yorùbá ti Ọdún 1988.* Pastoral Institute, Bodija, Ibadan. November 24-26.

Fadoro, J.O. (2007). Dialectology. Ibadan Distance Learning Centre, Ibadan.

## MÓDÙ II: ÌPÍN KEJÌ

## IṢẸ́ AKÍNKÙGBÉ (1978)

**1.0 Ìfáàrà**

Òǹkọ̀wé Akínkùgbé pín èdè Yorùbá sí ẹ̀ka márùn-ún. Àwọn wọ̀nyìí ni: (a) (b) Àárin Gbùngbùn (d) Gúsù Ìlà Oòrùn (e) Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn (ẹ) Gúsù Ìwọ̀ Oòrùn (f) Àríwá Ìlà Oòrùn.

**2.0 Èròngbà àti àfojúsùn**

Iṣẹ́ òǹkọ̀wé Akínkùgbé ni a dojú kọ ní ìpín yìí. Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà, akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè ṣe àlàyé tí ó kún tí ó sì yéni yéké lórí ọ̀nà márùn-ún tí òǹkọ̀wé yìí pín èdè Yorùbá sí.

**3.0 Ìbéèrè ìṣàájú**

Ọ̀nà mélòó ni òǹkọ̀wé Akínkùgbé pín ẹ̀ka-èdè Yorùbá si?

**4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

Ẹ jẹ́ kí a wo àwòrán ẹ̀ka èdè tí ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí:

**AKINKUGBE (1978)**

Yorùbá

**1**
Àríwá Ìlà Oòrùn (North Eastern)
↓
Yàgbà, Gbẹ̀dẹ̀, Ìjùmú, Ìkìrì, Ọ̀wọ̀rọ̀, Owé
Ìpínlẹ̀: Kwara, Kogi

**2**
Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn (North Western)
↓
Ẹ̀gbá, Ẹ̀gbádò Ọyọ́, Òǹkò, Ìgbómìnà
Ìpínlẹ̀: Ọ̀yọ́ àti Kwara
↓
Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn ni ó súnmọ́ Yorùbá Àjùmọ̀lò jùlọ

**3**
Àárin Gbùngbùn (Central)
↓
Ifẹ̀, Ìjẹ̀ṣà, Àkúrẹ́ & Èkìtì
↓
Ìpínlẹ̀: Ọ̀ṣun, Oǹdó àti Èkìtì

**4**
Gúsù Ìlà Oòrùn
↓
[South Eastern]
1.
2.
Ìjẹ̀bú, Ìkálẹ̀, Ìlàjẹ, Oǹdó, Ọ̀wọ̀
Ìpínlẹ̀: Ògùn àti Oǹdó

**5**
Gúsù Ìwọ̀ Oòrùn
↓
[South Western]
Sabẹ̀ àti Kétu
Ìpínlẹ̀: Ọ̀yọ́, Kwara
Benin Republicàti Tógò

Àwòrán òkè yìí fi ọ̀nà márùn-ún tí Oyèláran pín ẹ̀ka-èdè Yorùbá sí. Èyí ni:

1. Àríwá Ìlà Oòrùn tí àwọn ọmọ abẹ́ rẹ̀ jẹ́ Yàgbà, Gbẹ̀dẹ̀, Ìjùmú, Ìkìrì, Ọ̀wọ̀rọ̀, Owé, tí wọ́n ń sọ ní ìpínlẹ̀ Kwárà àti Kogí.
2. Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn níbí tí a ti rí: Ẹ̀gbá, Ẹ̀gbádò (Yewa), Ọ̀yọ́, Òǹkò, Ṣakí, Ìgbómìnà, tí wọ́n ń sọ ní ìpínlẹ̀ Ògùn, Ọ̀yọ́ àti Kwárà. A lè fi Ọ̀ṣun tí wọ́n ń sọ ní Ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun náà sí abẹ́ ìsọ̀rí yìí. Ìgbómìnà wà ní Ìlà Oògùn àti Ìpínlẹ̀ Kwárà. Oyèláran gbàgbọ́ pé Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn ni ó sún mọ́ Yorùbá àjùmọ̀lò jùlọ.
3. Ààrin Gbùngbùn tí à ń sọ ní Ifẹ̀, Ìjẹ̀ṣà, Àkúrẹ́ àti Èkìtì tí wọ́n wà ní Ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun, Oǹdó àti Èkìtì.
4. Gúsù Ìlà Oòrùn tí àwọn ọmọ abẹ́ rẹ̀ jẹ́ Ìjẹ̀bú, Ìkálẹ̀, Ìlàjẹ àti Ọ̀wọ̀ tí wọ́n ń sọ ní Ìpínlẹ̀ Ògùn àti Oǹdó.
5. Gúsù Iwọ̀ Oògùn

   Ní abẹ́ ẹ̀ka-èdè yìí ni a ti rí Ṣábẹ̀ẹ́ àti Kétu tí à ń sọ ní Kwárà, orílẹ̀ èdè Benin Republic àti Tógò.

## 5.0 **Ìsọníṣókí**

A ti gbé ẹ̀ka-èdè márùn-ún tí Akínkùgbé pín èdè Yorùbá sí yẹ̀wò. Àwọn márùn-ún náà ni Àríwá Ìlà Oòrùn, Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn, Ààrin Gbùngbùn, Gúsù Ìlà Oòrùn àti Gúsù Ìwọ̀ Oòrùn. A sì ti ṣe àlàyé àwọn ọmọ abẹ́ ẹ̀ka-èdè kọ̀ọ̀kan àti àwọn ìpínlẹ̀ tí a ti ń sọ wọ́n.

## 6.0 **Iṣẹ́ ṣíṣe**

(a) Dárúkọ ẹ̀ka-èdè márùn-ún tí Akínkùgbé pín èdè Yorùbá sí.

(b) Ṣàlàyé kíkún lórí wọn pẹ̀lú àwọn ìpínlẹ̀ tí a ti ń sọ wọ́n.

7.0 **Ìwé Ìtọ́kasí**


Adéníyì, H.R. àti Akinloyè Òjó (2005). *Ìlò èdè àti èdè Yorùbá.* African World Press, Inc.

Adétugbo, A. (1967). *The Yorùbá language in western Nigeria: its major dialect areas.* Ann Arbor, Michigan: University Microfilms International.

Adétugbo, A. (1982). Towards a Yorùbá dialectology, in Adébísí Afọláyan (ed). Yorùbá language and literature. Ibadan: University Press Limited and University of Ifẹ̀ Press, pp. 207-224.

Akínkùgbé, O.O. (1978). A comparative phonology of Yorùbá dialects; Iṣẹkiri and Igala. Ph.D. Thesis, Department of Linguistics, University of Ibadan, Unpublished.

Awóbùlúyì, O. (1988). *Àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá: Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Èdè Yorùbá ti Ọdún 1988.* Pastoral Institute, Bodija, Ibadan. November 24-26.

Fadoro, J.O. (2007). Dialectology. Ibadan Distance Learning Centre, Ibadan.

## MÓDÙ II: ÌPÍN KẸRIN

## IṢẸ́ AWÓBÙLÚYÌ (1998)

### 1.0 Ifáàrà

Òǹkọ̀wé Awóbùlúyì pín èdè Yorùbá sí ẹ̀ka márùn-ún Àwọn ẹ̀ka-èdè náà ni: (a) Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn (b) Àríwá Ìlà Oòrùn (d) Ààrin Gbùngbùn (e) Gúsù Ìlà Oòrùn àti (ẹ) Gúsù Ìwọ̀ Oòrùn.

### 2.0 Èròǹgbà àti àfojúsùn

Kókó ohun tí a fẹ́ gbéyẹ̀wò ní ìsọ̀rí yìí ni bí Ọ̀jọ̀gbọ́n Awóbùlúyì ṣe pín ẹ̀ka-èdè Yorùbá sí ọ̀nà márùn-ún. Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ lè ṣe àlàyé kíkún lórí ìpínsísọ̀rí ẹ̀ka-èdè tí Awóbùlúyì ṣe ní ọdún 1998.

### 3.0 Ìbéèrè ìṣàájú

Ọ̀nà mélòó ni Awóbùlúyì pín ẹ̀kà-èdè Yorùbá sí?

### 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Ẹ jẹ́ kí á wo iṣẹ́ òǹkọ̀wé Awóbùlúyì gẹ́gẹ́ bí ó ṣe pín ẹ̀ka-èdè Yorùbá sí ọ̀nà márùn-ún nínú àwòrán tí ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí:

Yorùbá

**1**

Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn
(North Western)
↓
Èkó, Àwórì, Ẹ̀gbádò,
Ọ̀yọ́, Ọ̀ṣun, Ìbọ̀lọ̀,
Ìgbómìnà.
(Àwọn ìpínlẹ̀ tí a ti ń
sọ wọ́n ni Èkó, Ọ̀yọ́,
Ọ̀ṣun àti Kwárà).
↓
Èyí ni Ọ̀jọ̀gbọ́n Awóbùlúyì
gbàgbọ́ pé ó súnmọ́
Yorùbá àjùmọ̀lò jùlọ

**2**

Àríwá Ìlà Oòrùn
(North Eastern)
↓
Ìyàgbà, Ìjùmù,
Ọ̀wọ̀rọ̀, Owé
[Ìpínlẹ̀ Kogí]

**3**

Ààrin Gbùngbùn
(Central)
↓
Ifẹ̀, Ìjẹ̀ṣà, Àkúrẹ́
& Mọ̀bà
↓
Ìpínlẹ̀ [Ọ̀ṣun,
Èkìtì àti Oǹdó]

**4**

Gúsù Ìlà Oòrùn
↓
[South Eastern]
↓
Ìjẹ̀bú, Ìkálẹ̀, Òndó,
Ọ̀wọ̀, Ọ̀bà Àkókó
(Ìpínlẹ̀ – Ògùn àti
Oǹdó)

**5**

Gúsù Ìwọ̀ Oòrùn
↓
[South Western]
↓
Sabẹ – Kétu
(Ànọ̀gó)
Ifẹ̀ (Togo)
Ẹ̀yìn odi
Nàìjíríà-
(Republic of
Benin àti Tógò)

Bí o bá wo àwòrán ẹ̀ka-èdè tí ó wà lókè yìí, wà á rí ọ̀nà márùn-ún tí Awóbùlúyì pín ẹ̀ka-èdè Yorùbá sí pẹ̀lú ọmọ abẹ́ ẹ̀ka-èdè kọ̀ọ̀kan àti àwọn ìpínlẹ̀ àti orílẹ̀ tí a ti ń sọ ìkọ̀ọ̀kan wọn.

## 5.0 Ìsọnísọ́kí

A ti ṣe àyẹ̀wò ẹ̀ka-èdè márùn-ún tí Ọ̀jọ̀gbọ́n Awóbùlúyì pín èdè Yorùbá sí. A ti rí àwọn ọmọ abẹ́ ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan àti àwọn ìpínlẹ̀ tí a ti ń sọ wọ́n.

## 6.0 Iṣẹ́ ṣíṣe

(a) Dárúkọ àwọn ẹ̀ka-èdè márùn-ún tí Ọ̀jọ̀gbọ́n Awóbùlúyì pín èdè Yorùbá sí.

(b) Sọ àwọn ọmọ abẹ́ ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan àti agbègbè tí a ti ń sọ wọ́n.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Adéníyì, H.R. àti Akinloyè Òjó (2005). *Ìlò èdè àti èdè Yorùbá.* African World Press, Inc.

Adétugbo, A. (1967). *The Yorùbá language in western Nigeria: its major dialect areas.* Ann Arbor, Michigan: University Microfilms International.

Adétugbo, A. (1982). Towards a Yorùbá dialectology, in Adébísí Afọláyan (ed). Yorùbá language and literature. Ibadan: University Press Limited and University of Ifẹ̀ Press, pp. 207-224.

Akínkùgbé, O.O. (1978). A comparative phonology of Yorùbá dialects; Iṣẹkiri and Igala. Ph.D. Thesis, Department of Linguistics, University of Ibadan, Unpublished.

Awóbùlúyì, O. (1988). *Àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá: Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Èdè Yorùbá ti Ọdún 1988*. Pastoral Institute, Bodija, Ibadan. November 24-26.

Fadoro, J.O. (2007). Dialectology. Ibadan Distance Learning Centre, Ibadan.

## MÓDÙ II: ÌPÍN KARÙN-ÚN

## IṢẸ́ ADÉNÍYÌ ÀTI ÒJÓ (2005)

### 1.0 Ìfáàrà

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, iṣẹ́ Adéníyì àti Òjó (2005) ni ó kún jù nínú àwọn iṣẹ́ márùn-ún tí a lò fún iṣẹ́ yìí. Àwọn òǹkọ̀wé yìí pín ẹ̀ka-èdè Yorùbá sí ọ̀nà méje ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Ìlà Oòrùn, Ìwọ̀ Oòrùn, Àríwá Ìlà Oòrùn, Ààrin Gbùngbùn, Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn, Gúsù Ìlà Oòrùn àti Gúsù Ìwọ̀ Oòrùn.

### 2.0 Èròǹgbà àti àfojúsùn

A ó ṣe àlàyé kíkún lórí ọ̀nà méje tí Adéníyì àti Òjó (2005) pín ẹ̀ka-èdè Yorùbá sí ní ìsọ̀rí yìí. Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́, ó yẹ kí akẹ́kọ̀ọ́ lè ṣàlàyé kíkún lórí iṣẹ́ yìí.

### 3.0 Ìbéèrè ìṣàájú

Dárúkọ ọ̀nà méje tí Adéníyì àti Òjó pín ẹ̀ka-èdè Yorùbá sí nínú iṣẹ́ wọn tí ó jáde ní ọdún (2005).

### 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Ẹ jẹ́ kí a wo àwọn ìpín méje tí Adéníyì àti Òjó pín ẹ̀ka-èdeYorùbá sí nínú àwòrán ìsàlẹ̀ yìí.

## IṢẸ́ ADÉNÍYÌ ÀTI ÒJÓ (2005)

**Yorùbá**

| 1 | 2 | 3 | 4 | 5 | 6 | 7 |
|---|---|---|---|---|---|---|
| Ìlà Oòrùn (Eastern Yorùbá)<br>↓<br>Ùkàrẹ́, Ọ̀bà àti Ìdó-Àní<br>↓<br>**Ìpínlẹ̀**<br>Oǹdó | Ìwọ̀ Oòrùn (Western Yorùbá)<br>↓<br>Ànàgó, Kétu, Ifẹ̀ (Tógò), Ọ̀họ̀rì, Sábẹ̀ẹ́<br>↓<br>Yorùbá<br>↓<br>Ẹ̀yìn odi Nàìjíríà (Republic of Benin àti Tógò) | Àríwá Ilà Oòrùn<br>↓<br>[North Eastern Yorùbá]<br>↓<br>Yàgbà, Bùnú, Ìjùmú, Owé, Gbẹ̀dẹ̀ àti Àyèré<br>↓<br>**Ìpínlẹ̀**<br>Kwárà àti Kogí | Ààrin Gbùngbùn<br>↓<br>[Central Yorùbá]<br>↓<br>Ifẹ̀, Ìjẹ̀ṣà, Àkúrẹ́, Èkìtì àti Mọ̀bà<br>↓<br>**Ìpịnlẹ̀**<br>Ọ̀ṣun, Oǹdó àti Èkìtì | Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn<br>↓<br>[North Western Yorùbá]<br>↓<br>Ọ̀yọ́, Òǹkò, Ọ̀ṣun, Ìbọ̀lọ̀ àti Ìgbómìnà<br>↓<br>**Ìpínlẹ̀**<br>Ògùn àti Oǹdó | Gúsù Ìlà Oòrùn<br>↓<br>[South-Eastern Yorùbá]<br>↓<br>Ìjẹ̀bú, Oǹdó, Ìkálẹ̀, Ìlàjẹ, Ọ̀wọ̀ àti Ìjọ́<br>↓<br>**Ìpínlẹ̀**<br>Ọ̀yọ́, Ọ̀ṣun àti Kwárà | Gúsù Ìwọ̀ Oòrùn<br>↓<br>[South Western Yorùbá]<br>↓<br>Èkó, Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ẹ̀gbádò<br>↓<br>**Ìpínlẹ̀**<br>Èkó àti Ògùn |

Tí o bá farabalẹ̀ wo àwòrán òkè yìí, o ó rí i pé Adéníyì àti Òjó pín ẹ̀ka-èdè Yorùbá sí ọ̀nà méje tí a ó ò gbé yẹ̀wò níbí.

1. **Yorùba Ìlà-Oòrùn**

Àwọn ọmọ abẹ́ ìsọ̀rí yìí ni Ùkàrẹ́, Ọ̀bà, Ìdó-Àní. Rántí pé a sọ ṣáájú pé abẹ́ ìsọ̀rí yìí ni Ào àti Olùkùmí náà wà. Ìpínlẹ̀ Oǹdó àti Delta ni a ti ń sọ àwọn ẹ̀ka-èdè wọ̀nyìí.

2. **Yorùbá Iwọ̀ Oòrùn**

Àwọn ọmọ abẹ́ ìsọ̀rí yìí ni Sábẹ̀ẹ́, Kétu (Ànọ̀gó), Ifẹ̀ (Tógò) àti Ọ̀họ̀rì. Sábẹ̀ẹ́ wà ní Kwárà, ó sì tún wà ní Benin Republic nígbà tí Kétu wà ní Benin Republic. Ufẹ̀ (Tógò) wà ní Tógò.

3. **Àríwá Ìlà Oòrùn**

Àwọn ọmọ abẹ́ ìsọ̀rí yìí ni Yàgbà, Bunu, Ìjùmnú, Owé, Gbẹ̀dẹ̀ àti Àyèré tí wọ́n ń sọ ní Ìpínlẹ̀ Kogí àti Kwárà.

4. **Ààrin Gbùngbùn**

Àwọn ọmọ abẹ́ ìsọ̀rí yìí ni Ifẹ̀, Ìjẹ̀ṣà, Àkúré, Mọ̀bà àti Èkìtì tí wọ́n ń sọ ní Ọ̀ṣun, Oǹdó àti Èkìtì.

5. **Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn**

Àwọn ọmọ abẹ́ ìsọ̀rí yìí ni Ọ̀yọ́, Ṣakí, Ọ̀nkò, Ìbàdàn, Ọ̀ṣun, Ìbọ̀lọ̀ àti Ìgbómìnà tí wọ́n ń sọ ní Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́, Ọ̀ṣun àti Kwárà. Ẹ̀ka-Èdè yìí ni ìgbàgbọ́ wà pé ó súnmọ́ Yorùbá èdè àjùmọ̀lò jùlọ.

6. **Gúsù Ìlà Oòrùn**

Àwọn ọmọ abẹ́ ìsọ̀rí yìí ni Ìjẹ̀bú, Oǹdó, Ìkálẹ́, Ọ̀wọ̀ àti Ìjọ́. Àwọn ìpínlẹ̀ tí wọ́n ti ń sọ wọ́n ni Ògùn àti Oǹdó.

7. **Gúsù Ìwọ̀ Oòrùn**

Àwọn ọmọ abẹ́ ìsọ̀rí yìí ni Èkó, Àwórì, Ẹ̀gbá àti Ẹ̀gbádò (Yewa) tí wọ́n ń sọ ní Ìpínlẹ̀ Èkó àti Ògùn ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà. A ó ṣe ìtúpalẹ̀ ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àwọn méjèèje ní Módù Kẹta-Ìpín 1-5.

5.0 **Ìsọníṣókí**

A ti ṣe àyẹ̀wò àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá méje tí Adéníyì àti Òjó ṣe ìpín rẹ̀ ní ọdún (2005). Ọ̀nà méje tí wọ́n pín èdè Yorùbá sí ni Ìlà Oòrùn, Ìwọ̀ Oòrùn, Àríwá Ìlà Oòrùn, Àárin Gbùngbùn, Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn, Gúsù Ìlà Oòrùn àti Gúsù Ìwọ̀ Oòrùn. A ti dárúkọ àwọn ọmọ abẹ́ ìsọ̀rí àti àwọn ìpínlẹ̀ tí wọ́n ti ń sọ àwọn ẹ̀ka-èdè méjèèje náà.

6.0 **Iṣẹ́ ṣíṣe**

(a) Dárúkọ àwọn ẹ̀ka-èdè méje tí Adéníyì àti Òjó (2005) pín Yorùbá sí.

(b) Ṣàlàyé àwọn ọmọ abẹ́ ìsọ̀rí àti ìpínlẹ̀ tàbi orílẹ̀-èdè tí a ti ń sọ wọ́n.

7.0 **Ìwé ìtọ́kasí**


Adéníyì, H.R. àti Akinloyè Òjó (2005). *Ìlò èdè àti èdè Yorùbá.* African World Press, Inc.

Adétugbo, A. (1967). *The Yorùbá language in western Nigeria: its major dialect areas.* Ann Arbor, Michigan: University Microfilms International.

Adétugbo, A. (1982). Towards a Yorùbá dialectology, in Adébísí Afọláyan (ed). Yorùbá language and literature. Ibadan: University Press Limited and University of Ifẹ̀ Press, pp. 207-224.

Akínkùgbé, O.O. (1978). A comparative phonology of Yorùbá dialects; Iṣẹkiri and Igala. Ph.D. Thesis, Department of Linguistics, University of Ibadan, Unpublished.

Awóbùlúyì, O. (1988). *Àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá: Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Èdè Yorùbá ti Ọdún 1988*. Pastoral Institute, Bodija, Ibadan. November 24-26.

Fadoro, J.O. (2007). Dialectology. Ibadan Distance Learning Centre, Ibadan.

## MÓDÙ III: ÌPÍN KÌN-ÍN-NÍ

## Ẹ̀KA MÉJE TÍ ADÉNÍYÌ ÀTI ÒJÓ PÍN ÈDÈ YORÙBÁ SÍ

### Yorùbá Ìlà Oòrùn àti Ìwọ̀ Oòrùn

A. **Ìlà Oòrùn**

A pín módù kẹta sí ìpín márùn-ún gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe Módù kìn-ín-ní àti Módù kejì. Ní Ìpín I, a ó ṣe àlàyé kíkún lórí Ẹ̀ka Ìlà Oòrùn àti Ìwọ̀ Oòrùn Yorùbá. A ó ṣe àyẹ̀wò Ẹ̀ka Àárin Gbùngbùn Yorùbá ní Ìpín Kejì. Ìpín Kẹta sọ̀rọ̀ lórí Ẹ̀ka Àríwá Ìlà Oòrùn, nígbà tí Ìpín Kẹrin sọ̀rọ̀ lórí Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn. Ní Ìpín Karùn-ún, ni a ti ṣe àlàyé lórí ẹ̀ka méjì tí ó kù, èyí ni Gúsù Ìlà Oòrùn àti Gúsù Ìwọ̀ Oòrùn.

### 1.0 Ìfáàrà

Yorùbá Ìlà Oòrùn jẹ́ ìpín tuntun. Adéníyì àti Òjó (2005) ni àwọn òǹkọ̀wé àkọ́kọ́ tí ó pín ẹ̀ká yìí. A lè sọ wí pé ohun tí ó ya ẹ̀ka yìí sọ́tọ̀ ni àwọn kọ́ńsónáǹtì méjì tí ó dàbí pé kò sí nínú àwọn ẹ̀ka èdè Yorùbá tí ó kù ni ó wà nínú ẹ̀ka èdè Yorùbá Ilà Oòrùn. Àwọn kọ́ńsónáǹtì yìí ni: /z/ àti /ɹ/. A ó ò ṣe àyẹ̀wò kíkún lórí eléyìí nínú ìsọ̀rí ẹ̀kọ́ wọ̀nyìí.

### 2.0 Èròǹgbà àti àfojúsùn

Kókó iṣẹ́ tí a fẹ́ ṣe ní ìsọ̀rí yìí ni láti ṣe àlàyé lórí àwọn àbùdá tí ó ya Yorùbá Ìlà Oòrùn àti ti Ìwọ̀ Oòrùn sọ́tọ̀. Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóò le è ṣe àlàyé kíkún lórí àwọn àbùdá yìí.

### 3.0 Ìbéèrè ìṣàájú

Dárúkọ àwọn ọmọ abẹ́ ìsọ̀rí yìí gẹ́gẹ́ bí a ti mẹ́nubàá ṣáájú ní Módù II.

### 4.0 Àwọn nǹkan tó se àrà ọ̀tọ̀ nínú Yorùbá Ìlà Oòrùn

1. /z/ má a ń jẹyọ dípò /dʒ/
   ɛza dípò ɛdʒa (fish)
   azá dípò adʒá (dog)
   àzɔ dípò àdʒɔ (gathering)

2. /ɹ/ má a ń jẹyọ dípò /s/
   /ɔɹã̀/ dípò /ɔsã̀/
   /ɹã́/ dípò /tã́/

3. /gw/ má a ń jẹyọ dípò /w/
ɛ̀gwá dípò ɛwá (ten)
ùgwé dípò ìwé (book)

4. /ɛ̃/ má a ń jẹyọ dípò /ĩ/
ùrɛ̃̀ dípò ìrĩ̀ (walk)
mɛ́rɛ̃ dípò mɛrĩ́ (four)

5. /u/ má a ń bẹ̀rẹ̀ àwọn ọ̀rọ̀ tí /i/ bẹ̀rẹ̀ ninú Yorùbá àjùmọ̀lò.
usɛ́ dípò iʃɛ́ (job)
ukù dípò ikù (stomach)
ukú dípò ikú (death)

6. /h/ má a ń dípò /w/ nínú àwọn ọ̀rọ̀ kan.
Àpẹẹrẹ:
/ùho/ dípò /ìwo/ (horn)
/uhò/ dípò /iwò/ (hole)
/òhú/ dípò /òwú/

7. /j/ má a ń jẹyọ ní ipò /w/
Owo → eyó (money)

8. /udɔ̃/ dípò /ɛrã/ (meat)
/ɔɹɔ̃́/ dípò /ɔsã̀/ (orange)
/ɹã/ dípò /tã́/ (finish)

9. /i/ má a ń jẹyọ dípò /e/ nínú:
/ʊlí/ dípò /ilé/ (house)

10. /a/ dípò /ɛ/
/anu/ dípò /ɛnũ/ (mouth)

11. /ɔ̃/ máa ń jẹyọ dípò /ũ/
/imɔ̃́/ dípò /imũ/ (nose)

Àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

5.0 **Ìsọníṣókí**

A ti mẹ́nuba àwọn àbùdá tí ó ya ẹ̀ka-èdè yìí sọ́tọ̀.

6.0 **Iṣẹ́ ṣíṣe**

Ṣàlàyé àwọn àbùdá tí ó ya ẹ̀ka-èdè yìí sọ́tọ̀.

7.0 **Ìwé ìtọ́kasí**

Adéníyì, H.R. àti Akinloyè Òjó (2005). *Ìlò èdè àti èdè Yorùbá.* African World Press, Inc.

Adétugbo, A. (1967). *The Yorùbá language in western Nigeria: its major dialect areas.* Ann Arbor, Michigan: University Microfilms International.

Adétugbo, A. (1982). Towards a Yorùbá dialectology, in Adébísí Afọláyan (ed). Yorùbá language and literature. Ibadan: University Press Limited and University of Ifẹ̀ Press, pp. 207-224.

Akínkùgbé, O.O. (1978). A comparative phonology of Yorùbá dialects; Iṣẹkiri and Igala. Ph.D. Thesis, Department of Linguistics, University of Ibadan, Unpublished.

Awóbùlúyì, O. (1988). *Àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá: Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Èdè Yorùbá ti Ọdún 1988.* Pastoral Institute, Bodija, Ibadan. November 24-26.

Fadoro, J.O. (2007). Dialectology. Ibadan Distance Learning Centre, Ibadan.

**B. Yorùbá Iwọ̀ Oòrùn**

1.0 **Ìfáàrà**

Ní ìsọ̀rí yìí, a ó ṣe àlàyé díẹ̀ lórí ẹ̀ka-èdè Ìwọ̀ Oòrùn Yorùbá.

2.0 **Èròǹgbà àti àfojúsùn**

Èròǹgbà wa nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni láti ṣe àlàyé díẹ̀ fún wa nípa ẹ̀ka-èdè yìí. Lẹ́yìn tí a bá ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí tán, akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè sọ ohun tí a kọ́ nínú ìsọ̀rí náà.

3.0 **Ìbéèrè ìṣàájú**

Dárúkọ àwọn ọmọ abẹ́ ẹ̀ka-èdè Ìwọ̀ Oòrùn Yorùbá tí o mọ̀ àti ìpínlẹ̀ tí a ti ń sọ wọ́n. Gẹ́gẹ́ bí àlàyé tí a ṣe ní Módù Kejì.

4.0 **Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

Gẹ́gẹ́ bí àlàyé tí a ti ṣe ṣáájú, àwọn ọmọ abẹ́ ìsọ̀rí yìí ni “Ànàgó, Kétu, Sábẹ̀ẹ́, àti Ifẹ̀ (Tógò)”. Àwọn ẹ̀ka-èdè wọ̀nyìí sì wọ́pọ̀ lẹ́yìn odi orílẹ̀-èdè Nàìjíríà bí i Benin

àti Tógò. Iṣẹ́ ìwádìí sì ń tẹ̀síwájú lórí àwọn àbùdá tí ó ya ẹ̀ka-èdè yìí sọ́tọ̀. Nítorí ìdí èyí, a kò tí ì lè ṣe àlàyé lórí àwọn àbùdá tí ó ya ìsọ̀rí yìí sọ́tọ̀.

## 5.0 Ìsọníṣókí

A ti dárúkọ àwọn ọmọ abẹ́ ìsọ̀rí yìí, a sì ti sọ pé ẹ̀yin odi orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ni wọ́n wọ́pọ̀ sí, fún àpẹẹrẹ, Benin àti Tógò.

## 6.0 Iṣẹ́ ṣíṣe

Sọ àwọn ohun tí o mọ̀ nípa ẹ̀ka-èdè Ìwọ̀ Oòrùn Yorùbá ní kúkúrú.

## 7.0 Ìwé ìtọ́kasí


Adéníyì, H.R. àti Akinloyè Òjó (2005). *Ìlò èdè àti èdè Yorùbá.* African World Press, Inc.

Adétugbo, A. (1967). *The Yorùbá language in western Nigeria: its major dialect areas.* Ann Arbor, Michigan: University Microfilms International.

Adétugbo, A. (1982). Towards a Yorùbá dialectology, in Adébísí Afọláyan (ed). Yorùbá language and literature. Ibadan: University Press Limited and University of Ifẹ̀ Press, pp. 207-224.

Akínkùgbé, O.O. (1978). A comparative phonology of Yorùbá dialects; Iṣẹkiri and Igala. Ph.D. Thesis, Department of Linguistics, University of Ibadan, Unpublished.

Awóbùlúyì, O. (1988). *Àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá: Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Èdè Yorùbá ti Ọdún 1988*. Pastoral Institute, Bodija, Ibadan. November 24-26.

Fadoro, J.O. (2007). Dialectology. Ibadan Distance Learning Centre, Ibadan.

## MÓDÙ II: ÌPÍN KEJÌ
## YORÙBÁ ÀÀRIN GBÙNGBÙN

### 1.0 Ìfáàrà

A ó ṣe àlàyé kíkún lórí àwọn àbùdá tí ó ya Yorùbá Ààrin Gbùngbùn sọ́tọ̀.

### 2.0 Èròǹgbà àti àfojúsùn

Kókó ohun tí ó jẹ wá lógún ní ìsọ̀rí yìí ni láti ṣe àlàyé àwọn àbùdá tí ó ya Yorùbá Ààrin Gbùngbùn sọ́tọ̀. Lẹ́yìn tí a bá ti ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóò le è ṣe àlàyé kíkún lórí àwọn àbùdá tí ó ya Yorùbá Ààrin Gbùngbùn sọ́tọ̀.

### 3.0 Ìbéèrè ìṣàájú

Dárúkọ àwọn ọmọ abẹ́ ẹ̀ka-èdè Yorùbá Ààrin Gbùngbùn gẹ́gẹ́ bí àlàyé tí a ṣe ní Módù Kejì.

### 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

**Àwọn ohun tó jẹ́ àrà ọ̀tọ̀ nínú Yorùbá Aàrin Gbùngbùn**

1. Fáwẹ̀lì pọ̀ nínú Yorùbá Ààrin Gbùngbùn ju ti Yorùbá tó kù lọ.
   Fáwẹ̀lì àìránmúpè mẹ́sàn-án: i e (a) o u   i ɛ (a) ɔ ω
   Fáwẹ́lì àránmúpè méje,
   Àpẹẹrẹ: ĩ ɛ̃ ɔ̃ ũ ã ω̃ ĩ
2. Àǹkóò fáwẹ̀lì (vowel harmony) wọ́pọ̀ nínú Yorùbá Ààrin Gbùngbùn. Ohun tí ó fa eléyìí ni pé fáwẹ́lì Yorùbá Ààrin Gbùngbùn pọ̀ ju ti àwọn ẹ̀ka Yorùbá tí ó kù.
3. Wọ́n má a ń lo ‘yè sí’ dípò ‘tani’
   Àpẹẹrẹ: “Yèsí e rè” dípò “Tanì yẹn?” (Ìjẹ̀ṣà)
   Èkìtì má a ń lo: “ì sɛ́ ɛ̀ ĩ́?” dípò “Tanì yẹn?”
4. Wọ́n má a ń lo kí tàbí yè é dípò ‘tí’
   Àpẹẹrẹ: “Asọ kí mọ fọ” dípò “Aṣọ tí mo fọ” (Èkìtì)
   “Aṣọ yèé mọ fọ” dípò
   “Aṣọ tí mo fọ̀” (The cloth I washed) (Ìjẹ̀ṣà)

5. Wọ́n má a ń lo ‘yún’ tàbí ‘mú’ dípò ‘lọ’.
“Mọ yún oko” dípò (Mo lọ oko) (Ìjẹ̀ṣà)
Mọ mú oko (Mo lọ oko) (Èkìtì)

6. Wọ́n má a ń lo /l/ dípò /n/
Olè li e rè – Olè ni (Ìjẹ̀ṣà)
Olè lɛ́ɛ̀ɛ̃́ – Olè ni (Èkìtì)

7. Wọ́n má a ń lo ‘wí’ dípò ‘pé’
‘Mo gbọ́ wí ọ́ lọ síbẹ̀’, dípò
‘Mo gbọ́ pé ó lọ síbẹ̀.’
Ìjẹ̀ṣà á ní:
“ọn í ọ lọ síbẹ̀” dípò
“Wọ́n sọ pé ó lọ síbɛ̀”

8. Fáwẹ́lì /ú/ má a ń jẹyọ ní ìbẹ̀rẹ̀ ọ̀rò. Àpẹẹrẹ:
ulé dípò /ilé/ (house)
uṣu dípò /iʃu/ (yam)
ùwé dípò /ìwé/ (book)
ùlù dípò /ìlú/ (drum)

9. Wọ́n má a ń lo /s/ dípò /ʃ/
/usɛ́/ dípò /iʃɛ́/ (job)
/usu/ dipò /iʃu/ (yam)
/ɛsĩn/ dípò ɛʃĩ/ (horse)
/àsà/ dípò /àʃà/ (culture)
/àsá/ dípò /àʃá/ (eagle)

10. Yẹn /jɛ̃/ kì í jẹyọ
Wọn a lo nì dípò yẹn.
Àpẹẹrẹ:
“ulé e nĩ̀” dípò “ilé yẹn”
Ìjẹ̀ṣà a má a lo ‘yèé’ dípò ‘yìí’. (This)
Ìjẹ̀ṣà má a ń lo ‘yùn’ dípò dùn (sweet). Fún àpẹẹrẹ:
“Iyán <u>yùn</u> lẹrun rin ín”, dípò:
Iyán <u>dùn</u> lẹ́nu <u>yín</u>.
(You enjoy eating pounded yam)

5.0 **Ìsọníṣókí**

A ti ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àbùda tí ó ya ẹ̀ka Ààrin Gbùngbùn sọ́tọ̀ ní ìpín yìí.

6.0 **Iṣẹ́ ṣíṣe**

Ṣe àlàyé àwọn àbùdá tí ó ya Yorùbá Ààrin Gbùngbùn sọ́tọ̀.

7.0 **Ìwé ìtọ́kasí**


Adéníyì, H.R. àti Akinloyè Òjó (2005). *Ìlò èdè àti èdè Yorùbá.* African World Press, Inc.

Adétugbo, A. (1967). *The Yorùbá language in western Nigeria: its major dialect areas.* Ann Arbor, Michigan: University Microfilms International.

Adétugbo, A. (1982). Towards a Yorùbá dialectology, in Adébísí Afọláyan (ed). Yorùbá language and literature. Ibadan: University Press Limited and University of Ifẹ̀ Press, pp. 207-224.

Akínkùgbé, O.O. (1978). A comparative phonology of Yorùbá dialects; Iṣẹkiri and Igala. Ph.D. Thesis, Department of Linguistics, University of Ibadan, Unpublished.

Awóbùlúyì, O. (1988). *Àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá: Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Èdè Yorùbá ti Ọdún 1988*. Pastoral Institute, Bodija, Ibadan. November 24-26.

Fadoro, J.O. (2007). Dialectology. Ibadan Distance Learning Centre, Ibadan.

## MÓDÙ II: ÌPÍN KẸTA
## YORÙBÁ ÀRÍWÁ ÌLÀ OÒRÙN

1.0 **Ìfáàrà**

Ní ìsọ̀rí yìí, a ó ṣe àyẹ̀wò kíkún àwọn àbùdá tí ó ya Àríwá Ìlà Oòrùn Yorùbá sọ́tọ̀ gédéńgbé.

**1. Èròǹgbà àti àfojúsùn**

Kókó ohun tí a ó ṣe ní ìsọ̀rí yìí ni láti sẹ alàyé kíkún lórí àwọn àbùdá tí ó ya Àríwá Ìlà Oòrùn sọ́tọ̀. Lẹ́yìn tí a bá ti ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀wọ́ yóò le è ṣe àlàyé àwọn àbùdá tí ó ya ẹ̀ka-èdè yìí sọ́tọ̀.

3.0 **Ìbéèrè ìṣàájú**

Dárúkọ àwọn ọmọ abẹ́ ìsọ̀rí yìí gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ní Módù Kejì.

4.0 **Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

1. /p/ àti /k͡p/ má a ń jẹyọ

Ohun gbogbo → bérékpo

àdá → èpià

enũ → ɔnã → arũkpɔ̀nã̀

2. /gh/ má a ń dípò /w/

ewé → eghé

ìwɔ → ìghɔ

wò → ghò

3. /s/ má a ń dípò /ʃ/

| | | | |
|---|---|---|---|
| isu | dípò | iʃu | (yam) |
| ɛsĩ | dípò | ɛʃĩ | (horse) |
| ɛsɔ́ | dípò | ɛ̀ʃɔ́ | (guard) |

4. /g/ má a ń dípò /dʒ/

Ibogì dípò ibojì (grave)

5. /ʃ/ má a ń dípò /s/
sũ̀ → ʃì

6. /h/ má a ń dípò /s/

sùn → hũ̀

sɔ̀rɔ̀ → hɔ̀hɔ̀

7. /h/ tàbí /j/ má a ń dípò f

hṹ (give) dípò /fṹ/

jí (give) dípò /fṹ/

8. /éèé/ má a ń dípò kìí

éèé ṣe olè dípò kìí ṣe olè

éèé dʒɛ dípò kìí dʒɛ

éèé sùn dípò kìí sũ̀

"Ṣadé mɔ̃̀ mĩ́ já" dípò "Ṣadé kò mɔ̃ mĩ́"

9. Ọ̀rọ̀ orúkọ tàbí àpólà ọ̀rọ̀ orúkọ méjì le tẹ̀lé ara wọn.

O gbá mi lẹ́nu → Ó gbá maánu

## 5.0 Ìsọníṣókí

A ti ṣe àlàyé àwọn àbùdá tí ó ya Àríwá Ìlà Oòrùn Yorùbá sọ́tọ̀ ní ìsọ̀rí yìí.

## 6.0 Iṣẹ́ ṣíṣe

Ṣe àlàyé kíkún lórí àwọn àbùdá tí ó ya Yorùbá Àríwá Ìlà Oòrùn sọ́tọ̀.

7.0 **Ìwé ìtọ́kasí**


Adéníyì, H.R. àti Akinloyè Òjó (2005). *Ìlò èdè àti èdè Yorùbá.* African World Press, Inc.

Adétugbo, A. (1967). *The Yorùbá language in western Nigeria: its major dialect areas.* Ann Arbor, Michigan: University Microfilms International.

Adétugbo, A. (1982). Towards a Yorùbá dialectology, in Adébísí Afọláyan (ed). Yorùbá language and literature. Ibadan: University Press Limited and University of Ifẹ̀ Press, pp. 207-224.

Akínkùgbé, O.O. (1978). A comparative phonology of Yorùbá dialects; Iṣẹkiri and Igala. Ph.D. Thesis, Department of Linguistics, University of Ibadan, Unpublished.

Awóbùlúyì, O. (1988). *Àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá: Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Èdè Yorùbá ti Ọ *dún 1988*. Pastoral Institute, Bodija, Ibadan. November 24-26.

Fadoro, J.O. (2007). Dialectology. Ibadan Distance Learning Centre, Ibadan.

## MÓDÙ II: ÌPÍN KẸRIN

## YORÙBÁ ÀRÍWÁ ÌWỌ̀ OÒRÙN

1.0 **Ìfáàrà**

Kókó ohun tí a fẹ́ yẹ̀wò ní ìsọ̀rí yìí ni àwọn àbùdá tí ó ya Yorùbá Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn sọ́tọ̀.

2.0 **Èròǹgbà àti àfojúsùn**

A ó ṣe àlàyé lórí àwọn nǹkan tí ó mú kí Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn Yorùbá yàtọ̀ sí àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá tí ó kù. Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ á lè ṣe àlàyé kíkún lórí àwọn àbùdá yìí.

3.0 **Ìbéèrè ìṣàájú**

Sọ àwọn ọmọ abẹ́ èka-èdè yìí àti ìpínlẹ̀ tí a ti ń sọ wọ́n gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ní Módù 2.

4.0 **Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

1. /u/ kìí jẹyọ ní ìbẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀.

   Ìwé, ilé, ìlú, ilẹ̀ abbl (book, house, town & land)

2. /ɛ̃/ má a ń jẹyọ fún àpẹẹrẹ:

   Onko

   ɔʃã̀ → ɔsɛ̃́ (afternoon) ɔ̀kã → ɔ̀kɛ̃ (one)

   ɔsã̀ → ɔsɛ̃̀ (orange)      náà → nɛ̃́ɛ̃̀ (that)

   inã́ → inɛ̃́ (fire)

3. /s/ má a ń dípò /ʃ/

   ɛsĩ      dípò    ɛ̀ʃĩ (horse)

   ɛ̀sĩ̀      dípò    ɛ̀ʃĩ̀ (religion)

   esĩsĩ    dípò    eʃĩʃĩ (housefly)

   ɛ̀sĩ́      dípò    ɛ̀ʃĩ́ (disgrace)

4. /ʃ/ má a ń di /tʃ/ in Onko

Àpẹẹrẹ:

iʃɛ́ → itʃɛ́ (job

eʃĩʃĩ → etʃĩtʃĩ (housefly)

ɛʃĩ → ɛtʃĩ (horse)

5. /w/ má a ń di /h/

Àpẹẹrẹ:

iwò → ihò (hole)

ìwo → ìho (horn)

ewúrɛ → ehúrɛ́ (goat)

6. /n/ má a ń di /l/

Àpẹẹrẹ:

Tani → tali (who)

Ó nĩ́ → ó lí (he has)

7. Kpé dípò kéfú

ibo dípò ibusí

ìgbà sí dípò ‘ìgbà wo’.

8. Àwọn ọ̀rọ̀ kọ̀ọ̀kan wà tí ó ṣe àjèjì (yàtọ̀) sí èyíí tí a ń gbọ́ ní àwọn Yorùbá tí ó kù.

Èrúwà/Ìsẹ́yìn

bàbá → ògbónĩ

àgbàdo → yangan tàbí láńgbé

Igbá → Kpàkátà

odʒúde → búkà

ɛkpà → yéré

Ó sọ pé → Ó sọ kéfú

Ó yà mí lẹ́nu pé → Ó yà mí lẹ́nu kéfú ó wá.

Ó wá.

5.0 **Ìsọníṣókí**

A ti sọ àwọn àbùdá méjọ tí ó ya Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn Yorùbá sọ́tọ̀ ní ìsọ̀rí yìí.

6.0 **Iṣẹ́ ṣíṣe**

Sọ àwọn àbùdá méjọ tí ó ya Àríwá Ìwọ̀ Oòrùn Yorùbá sọ́tọ̀.

7.0 **Ìwé ìtọ́kasí**


Adéníyì, H.R. àti Akinloyè Òjó (2005). *Ìlò èdè àti èdè Yorùbá.* African World Press, Inc.

Adétugbo, A. (1967). *The Yorùbá language in western Nigeria: its major dialect areas.* Ann Arbor, Michigan: University Microfilms International.

Adétugbo, A. (1982). Towards a Yorùbá dialectology, in Adébísí Afọláyan (ed). Yorùbá language and literature. Ibadan: University Press Limited and University of Ifẹ̀ Press, pp. 207-224.

Akínkùgbé, O.O. (1978). A comparative phonology of Yorùbá dialects; Iṣẹkiri and Igala. Ph.D. Thesis, Department of Linguistics, University of Ibadan, Unpublished.

Awóbùlúyì, O. (1988). *Àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá: Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Èdè Yorùbá ti Ọdún 1988*. Pastoral Institute, Bodija, Ibadan. November 24-26.

Fadoro, J.O. (2007). Dialectology. Ibadan Distance Learning Centre, Ibadan.

## MÓDÙ III: ÌPÍN KARÙN-ÚN
## GÚSÙ ÌLÀ OÒRÙN ÀTI GÚSÙ ÌWỌ̀ OÒRÙN

A. **Gúsù Ìlà Oòrùn**

1.0 **Ìfáàrà**

Ní abẹ́ ìsọ̀rí yìí, a ó ṣe àlàyé àwọn àbùdá tí ó ya Gúsù Ìlà Oòrùn Yorùbá sọ́tọ̀.

2.0 **Ìbéèrè ìṣàájú**

Dárúkọ àwọn ọmọ abẹ́ ìsọ̀rí yìí gẹ́gẹ́ bí a ti mẹ́nubàá tẹ́lẹ̀.

3.0 **Èròǹgbà àti àfojúsùn**

Kókó iṣẹ́ tí a ó ṣe níbí ni láti wo àwọn àbùdá tí ó ya ẹ̀ka-èdè Gúsù Ìlà Oòrùn Yorùbá sọ́tọ̀. Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóò le è ṣe àlàyé kíkún lórí àwọn abùdá yìí.

4.0 **Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

1. /u/ má a ń bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ dípò /a/ tàbí /i/.

   Àpẹẹrẹ:

   /úlí/ dípò /ilé/ (house)

   /urɛ̃/ dípò /irĩ/ (iron)

   /uwɔ̃̀/ dípò /awɔ̃̀/ (tongue)

2. /ɛ̃/ má a ń dípò /ĩ/

   mɛ́rɛ̃̀lá (fourteen) dípò mɛrĩ̀lá

   ɔmakũ̀rĩ (boy) dípò ɔmɔkũ̀rĩ

   ɛmɛ̃ dípò ɛ̀jĩ (you)

3. /j/ má a ń dípò /w/

   ɛwɛ̃ dípò ɛ̀jĩ (Ìjẹ̀bú)

   ɛ̀ǹwɛ̃ dípò ɛ̀jĩ (Oǹdó)

4. /z/ má a ń dípò /dʒ/

   Ozú dípò odʒú (eye)

   zɛũ dípò dʒɛũ (eat)

   zà dípò dʒà (fight)

5. /gw/ má a ń dípò /w/

(Ọ̀wọ̀) ɛ̀gwá dípò ɛ̀wá (ten)

(Ìkálẹ̀) gwɔ̀ dípò wɔ̀ (enter).

6. /h/ má a ń dípò s

hũ̀ dípò sũ̀ (sleep)

ɛhɛ̀ dípò ɛsɛ̀ (leg)

hó dípò só.

7. /n/ má a ń dípò /l/

nɛ̃́jɛ̃ dípò lɛ́jɛ

nówó dípò lówó

nɔ́lá dípò lɔ́lá

8. Wọn kì í lo pé, wọn á má a lo 'fi' dípò rẹ̀.

'Ó sɔ kpé' a di 'o fɔ̀ fí'

'wɔ̃̀ kpe' a ti 'lɔ ilé'

a di 'wɔ̃́ fi a ti re ulí'

9. /gh/ má a ń dípò /w/

ìghɔ dípò ìwɔ (you)

ɔghɔ́ dípò ɔwɔ́ (hand)

oghó dípò owó (money)

5.0 **Ìsọnísọ́kí**

Ní ìsọ̀rí yìí, a ti mẹ́nuba àwọn ohun tí ó ya Yorùbá Gúsù Ìlà Oòrùn sọ́tọ̀.

6.0 **Iṣẹ́ ṣíṣe**

Ṣe àlàyé kíkún lórí àwọn ohun tí ó ya ẹ̀ka-èdè yìí sọ́tọ̀.

## 7.0 **Ìwé ìtọ́kasí**


Adéníyì, H.R. àti Akinloyè Òjó (2005). *Ìlò èdè àti èdè Yorùbá.* African World Press, Inc.

Adétugbo, A. (1967). *The Yorùbá language in western Nigeria: its major dialect areas.* Ann Arbor, Michigan: University Microfilms International.

Adétugbo, A. (1982). Towards a Yorùbá dialectology, in Adébísí Afọláyan (ed). Yorùbá language and literature. Ibadan: University Press Limited and University of Ifẹ̀ Press, pp. 207-224.

Akínkùgbé, O.O. (1978). A comparative phonology of Yorùbá dialects; Iṣẹkiri and Igala. Ph.D. Thesis, Department of Linguistics, University of Ibadan, Unpublished.

Awóbùlúyì, O. (1988). *Àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá: Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Èdè Yorùbá ti Ọdún 1988.* Pastoral Institute, Bodija, Ibadan. November 24-26.

Fadoro, J.O. (2007). Dialectology. Ibadan Distance Learning Centre, Ibadan.


# B. Gúsù Ìwọ̀ Oòrùn

## 1.0 **Ìfáàrà**

Kókó ohun tí ó jẹ wá lógún ní ìsọ̀rí yìí ni láti ṣe àlàyé àwọn àbudá tí ó ya Gúsù Ìwọ̀ Oòrùn Yorùbá sọ́tọ̀.

## 2.0 **Èròǹgbà àti Àfojúsùn**

A ó ò ṣe àlàyé àwọn àbùdá tí ó ya Gúsù Ìwọ̀ Oòrùn Yorùbá sọ̣tọ̀. Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóò le è ṣe àlàyé lórí àwọn àbùdá yìí.

## 3.0 **Ìbéèrè ìṣàájú**

Dárúkọ àwọn ọmọ abẹ́ ìsọ̀rí yìí gẹ́gẹ́ bí a ti mẹ́nubàá ṣáájú.

4.0 **Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

1. Ìfàgùn fáwẹ́lì, lẹ́yìn ìpajẹ kọ́nsónáǹtì

   Ìgbálẹ̀ → Ààálẹ̀ (broom)

   Òwúrọ̀ → ààrọ̀ (morning)

   Òkùǹkù → òòkù (darkness)

2. /u/ kì í jẹyọ ní ìbẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ ní ìbámu pẹ̀lú Yorùbá àjùmọ̀lò.

   /ilé/, /ìlú/, /ìlù/, & /ilɛ̀/

3. Nínú Ẹ̀gbá àti Ẹ̀gbádò, fáwẹ́lì /a/ má a ń dípò /ɔ/.

   Àpẹẹrẹ: lɔ → la, (go)

   lɔ kpè é wá → la kpèé wá.

   lɔ bi í léèrè → la bi í lɛ́ɛ́bi

4. Fáwẹ́lì /ɛ̃/ - ɛ̃̀ má a ń jẹyọ ní Ẹ̀gbá àti Àwórì. Àpẹẹrẹ:

   "ìlú le nísìnyìí" á di
   "ìlú le sè-èn yìí"

5. /l/ má a ń dípò /n/

   n → l

   nĩ - lí (have)

   Adéníyì → Adélíyì

   Mo lí àdá dípò 'Mo ní àdá'.

6. Àwọn ọ̀rọ̀ kan wà tí ó ṣe àjèjì. Fún àpẹẹrẹ:

   orí → orúwɔ

   Àdá → èélé

5.0 **Ìsọníṣókí**

A ti mẹ́nuba àwọn àbùdá tí ó ya àwọn ẹ̀ka-èdè yìí sọ́tọ̀.

6.0 **Iṣẹ́ ṣíṣe**

Ṣe àlàyé àwọn àbùdá tí o mọ̀ tí ó ya ẹ̀ka-èdè yìí sọ́tọ̀.

## 7.0 **Ìwé ìtọ́kasí**


Adéníyì, H.R. àti Akinloyè Òjó (2005). *Ìlò èdè àti èdè Yorùbá.* African World Press, Inc.

Adétugbo, A. (1967). *The Yorùbá language in western Nigeria: its major dialect areas.* Ann Arbor, Michigan: University Microfilms International.

Adétugbo, A. (1982). Towards a Yorùbá dialectology, in Adébísí Afọláyan (ed). Yorùbá language and literature. Ibadan: University Press Limited and University of Ifẹ̀ Press, pp. 207-224.

Akínkùgbé, O.O. (1978). A comparative phonology of Yorùbá dialects; Iṣẹkiri and Igala. Ph.D. Thesis, Department of Linguistics, University of Ibadan, Unpublished.

Awóbùlúyì, O. (1988). *Àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá: Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Èdè Yorùbá ti Ọdún 1988*. Pastoral Institute, Bodija, Ibadan. November 24-26.

Fadoro, J.O. (2007). Dialectology. Ibadan Distance Learning Centre, Ibadan.

**ÀWỌN ÀKÓJỌPỌ̀ Ọ̀RỌ̀ YORÙBÁ LÉỴÌN ODI NÀÌJÍRÍÀ (ADETUGBỌ, 2001)**

| | ÀNÀGÓ/KÉTU | MEANING | YORÙBÁ/COMMENTS |
|---|---|---|---|
| 1. | Ere/Gyere | Play | eré |
| 2. | Omi | Water, juice | omi |
| 3. | Ọkà | Cornmeal | ọkà |
| 4. | Bàbá | Father | bàbá |
| 5. | Ackra/akara | Bean cake | àkàrà |
| 6. | Agidi | Cornmeal | àgidi |
| 7. | Aye | World, life | ayé |
| 8. | Bayawo | Are you married? | ìyàwó (wife) |
| 9. | Buru | Bad, wicked | buru |
| 10. | Agutan | Sheep | àgùtàn |
| 11. | Awure | Goat | ewúrẹ́ |
| 12. | Baguda, gbaguda | Cassava | gbágùúdà |
| 13. | Dúdú | Albino | dúdú (black, dark) |
| 14. | Oogu | Medicine | oògùn |
| 15. | Agbado | Corn | àgbàdo |
| 16. | Aja | Dog | ajá |
| 17. | Akuko | Cock | àkùkọ |
| 18. | Ata | Pepper | ata |
| 19. | Aṣọ | Cloth | aṣọ |
| 20. | Babalúwayé | The supreme king | ọbalúwayé |
| 21. | Okuta | Cock, stone | òkúta |
| 22. | Dudu | Type of drum | dùndún |
| 23. | Jije | Edible | jíjẹ |
| 24. | Eran | Fish | ẹran |
| 25. | Elede | Pig | ẹlẹ́dẹ̀ |
| 26. | Ẹran | Meat | ẹran |
| 27. | Ẹja | Kalalu | ẹran |

| | | | |
|---|---|---|---|
| 28. | Esogi | Banana | esogi (fruit) |
| 29. | Fu | Give | fún |
| 30. | Oku | Spirit | òkú (dead) |
| 31. | Esi | Horse | ẹṣin |
| 32. | Ila | Okro | ilá |
| 33. | Malu | Cow | màlúù |
| 34. | Koko | Dasheen | kókò |
| 35. | Nyakanyaka | Disorderly | yánkanyànkan |
| 36. | Ile | House | ilé |
| 37. | Ilu | Drum | ìlù |
| 38. | Akuro | Vegetable farm | àkùrọ̀ |
| 39. | Agumu | Medicine | àgúnmu |
| 40. | Kabokabo | Poorly, confused | kàbakàba |
| 41. | Kpa | Kill | paá |
| 42. | Obe | Knife | ọ̀bẹ |
| 43. | Omode | Child | ọmọdé |
| 44. | Oti | Rum/Alcoholic Beverage | ọtí (líle) |
| 45. | Owo | Money | owó |
| 46. | Obo | Vagina | òbò |
| 47. | Ogede | Banana | ọ̀gẹ̀dẹ̀ |
| 48. | Biri/biri | Woman | obìnrin |
| 49. | Usu | Yam | iṣu |
| 50. | Yaya | Grandmother | ìyá (mother)/ìyá (grandmother) |
| 51. | Wuruwuru | Untidy | wúruwùru |
| 52. | Werewe | Small, diminutive | wẹ́wẹ́ |
| 53. | Owo | Hand | ọwọ́ |
| 54. | Soso | Only | ṣoṣo |

| | | | |
|---|---|---|---|
| 55. | Sun | Sleep | sùn |
| 56. | Ole/le | Thief | olè |
| 57. | Okuri/akari | Man/male | ọkùnrin |
| 58. | Oko/ko | Penis | okó |
| 59. | Ukute | Rat | èkúté |
| 60. | Obi/V bi | Kolanut | obì |
| 61. | Ẹkọ | Corn paste | ẹ̀kọ |
| 62. | Fufu | Tumtun | fùfú |
| 63. | Egusi | Melon | ègúsí |
| 64. | Gbegiri | Bean/pea soup | gbẹ̀gìrì |
| 65. | Abere, agyere | Infidelity | àgbèrè |
| 66. | Asaro | Breadfruit | àṣáró (porridge) |
| 67. | Se | Do | ṣe |
| 68. | Eni | One | ení |
| 69. | Ago | Glory | ògo |
| 70. | Abara | Enemy | ọ̀tá |
| 71. | Ina | Fire | iná |
| 72. | Awori | Group name | awórì |
| 73. | Oluwa | Lord | olúwa |
| 74. | Sin | Serve, worship | sìn |
| 75. | Wa | Exist, be | wà |
| 76. | Oke | Height, hill | òkè |
| 77. | Ya | Detour | yà |
| 78. | Iwo | Cult signal | eríwo yà |
| 79. | Fufu | White | funfun |
| 80. | Ofofo | Liar | olófòófó (tale-bearer, gossip) |
| 81. | Jafara | Be slack, indolent | jáfara |
| 82. | Mase | Do not | máṣe |

| | | | |
|---|---|---|---|
| 83. | Loni | Today | lónìí |
| 84. | Jebu | Clan name | ìjẹ̀bú |
| 85. | Si | Towards | sí |
| 86. | E ni | Person | ẹni |
| 87. | Sowo | Trade | ṣòwò |
| 88. | Eniyan | Person | ènìyàn |
| 89. | La | Rich | là |
| 90. | Ѐp̣à | Groundnut | epo |

**Lukumi**

1. Abo Adìẹ: Hen Abo: Ram
2. Abẹ̀dẹ̀: Fan
3. Aberinkula: Uninitiated Person or Thing
4. Abúrè: Brother, Sister (younger)
5. Adé: Crown
6. Afẹ́fẹ́: Wind
7. Ago: Ask for Permission, Knock Knock
8. Agogo: Bell, Hour
9. Àgòyà: Enter
10. Àìkú: Health, Long Life
11. Ajúb̀a: We Salute You...
12. Akukọ: Rooster
13. Àlà: White Cloth
14. Àlá: Dream
15. Alàgbà, Àgbàlagbà: Respected
16. Al̀ejò: Outsider
17. Ànà: Road
18. Àrá: Thunder

| | | |
|---|---|---|
| 19. | Araye: | Envy, Ill-Will |
| 20. | Àrùn: | Sickness |
| 21. | Asha: | Cigar, Tobacco |
| 22. | Àshẹ: | So Be It, The Spiritual Power of the Universe, Talent |
| 23. | Ashelu: | Police |
| 24. | Aṣhéogun Ọ̀tá: | Victory Over Enemies (Aṣẹ́gun) |
| 25. | Ashere: | Maraca, Rattle |
| 26. | Aṣhọ: | Cloth |
| 27. | Atana: | Candle |
| 28. | Awo: | Secret |
| 29. | Ayan: | Orisha of Drums |
| 30. | Bàbá: | Father |
| 31. | Babaláwo: | Father of the Secrets |
| 32. | Babalóòṣhà: | Father of Òrìṣhà, Priest |
| 33. | Busi: | Bless |
| 34. | Dìde: | Rise |
| 35. | Dúdú: | Dark |
| 36. | Egun: | The Dead |
| 37. | Eiyẹlé: | Dove, Pigeon |
| 38. | Ẹja: | Fish |
| 39. | Ẹ̀jẹ̀: | Blood |
| 40. | Ẹjọ́: | Court Case |
| 41. | Ẹ̀kọ: | Corn Meal |
| 42. | Eku: | Hutia |
| 43. | Ẹkùn: | Leopard |
| 44. | Ekpo: | Palm Oil |
| 45. | Ẹní: | Mat |
| 46. | Ẹni: | Person |
| 47. | Ẹsẹ̀: | Foot |

| | | |
|---|---|---|
| 48. | Ẹyin: | Egg |
| 49. | Fẹ́: | Love |
| 50. | Foríbalẹ̀: | Salute by Prostrating |
| 51. | Fún: | For, Give |
| 52. | Funfun: | White |
| 53. | Gbogbo: | All |
| 54. | Gidigidi: | Very Much |
| 55. | Iná: | Fire |
| 56. | Ibu: | Stream, River |
| 57. | Ibae Baye T'orun: | Rest in Peace (Salute to the Dead) |
| 58. | Igbá: | Calabash |
| 59. | Ikú: | Death |
| 60. | Ilé: | House |
| 61. | llẹ̀: | Ground, Land |
| 62. | Ìlẹ̀kùn: | Door |
| 63. | Ire: | Blessings |
| 64. | Ìràwọ̀: | Star |
| 65. | Iṣhu: | African Yam |
| 66. | Iworo: | Priest |
| 67. | Ìyá: | Mother |
| 68. | Ìyálòòṣhà: | Mother of Orisha, Priestess |
| 69. | Ìyàwó: | Bride Juba: Salute |
| 70. | Kòsí: | There is No |
| 71. | Kúnlẹ̀: | Kneel |
| 72. | Lọ: | Go |
| 73. | Maferefun: | Praise Be To... |
| 74. | Mi: | My |
| 75. | Mo: | I |
| 76. | Modúcúe: | Thank You |

| | | |
|---|---|---|
| 77. | Moforíbalẹ̀: | I Salute You By Prostrating |
| 78. | Mojúbà: | I Salute You |
| 79. | N lọ: | Is Going |
| 80. | Oba: | King |
| 81. | Obì: | Coconut, Obi Kola Nut |
| 82. | Obìnrin: | Woman |
| 83. | Odò: | River |
| 84. | Òdòdó: | Flower |
| 85. | Ofun: | White Chalk (made with eggshells) |
| 86. | Òfò: | Loss |
| 87. | Ogun: | Witchcraft |
| 88. | Òkun: | Sea, Ocean |
| 89. | Òkè: | Mountain |
| 90. | Ọkọ: | Man, Husband |
| 91. | Olo: | Owner, On Who Has... |
| 92. | Olúwo: | Lord of Awos (Babaláwo who became an òrìṣhà priest beforehand) |
| 93. | Omi Dúdú: | Coffee |
| 94. | Omi: | Water |
| 95. | Ọmọ: | Child |
| 96. | Ọ̀nà: | Road |
| 97. | Oní: | Owner of |
| 98. | Ọ̀pọ̀lọpọ̀: | Plenty |
| 99. | Orí: | Head |
| 100. | Òrí: | Cocao Butter |
| 101. | Ọ̀run: | Heaven |
| 102. | Òrùn: | Sun |
| 103. | Oṣhé: | Double Headed Axe |
| 104. | Òsogbo: | Negative Influence |

105. Oti: Rum
106. Owó: Money
107. Owu: Cotton
108. Oyin: Honey
109. Ṣhiṣhẹ́: Work
110. Súre fún: Bless
111. Tèmi: My, Mine
112. Tìẹ: Your
113. Timbelese: At the Feet of...
114. Tóbi: Who Gave Birth
115. Tutù: Cool, Fresh
116. Wá: Come
117. Wani: Who Come
118. Yèyé: Mama

**Ìsọníṣókí**

Abala yìí ṣe ìgbékalẹ̀ àwọn ọ̀rọ̀ tí Ọ̀jọ̀gbọ́n kójọ ní ọdún díẹ̀ sẹ́yìn. Eléyìí ni òtítọ́ ní òǹkọ̀wé yìí jẹ́ ẹ̀ka èdè Yorùbá lẹ́yiddi Nàìjíríà láti ọdún 1967.

| **Kọ́ńsónáǹtì** | **Fònẹ́tíìkì** | **Àpẹẹrẹ** |
|---|---|---|
| b – B | b bá ọ̀bọ | bá, ọ̀bọ |
| d – D | d dé dùn | dé, dùn |
| f – F | f fẹ́ fọ̀ | fẹ́, fọ̀ |
| g – G | g ga àga | ga, àga |
| gb – Gb | g͡b gbọ́ gbà | gbọ́, gbà |
| h – H | h he họ | he, họ |

| **Kọ́nsónáǹtì Lẹ́tà Kékeré** | **Lẹ́tà Ńlá** | **Fònẹ́tîìkì** | **Àpẹẹrẹ** |
|---|---|---|---|
| j | J | dʒ | Ajá, jó |
| k | K | k | Ọkà, ẹkọ |
| l | L | l | Là, lọ |
| m | M | m | Mú, Mọ̀ |
| n | N | n | Nà, ni |
| p | P | k͡p | Apá, pọ̀ |
| r | R | r | Rí, rà |
| s | S | s | Sùn, sá |
| ṣ | S | ʃ | Ṣe, ṣà |
| t | T | ti | Tà, tán |
| w | W | w | wá, wò |
| y | Y | j | yà, yọ |

**Fáwẹ́lì**

| | | | | **Àpẹẹrẹ** |
|---|---|---|---|---|
| 1. | a | A | a | yọ |
| 2. | e | E | e | edé |
| 3. | ẹ | Ẹ | ɛ | ẹja, ajá |
| 4. | ọ | Ọ | ɔ | ọba, bà |
| 5. | u | U | u | tú |
| 6. | an | AN | ã | tán |
| 7. | ẹn | ẸN | ɛ̃ | ìyẹn |
| 8. | in | IN | ĩ | ìgbín |
| 9. | ọn | ỌN | ɔ̃ | pọn |
| 10. | un | UN | ũ | fún |

**Ẹ̀rí Adétugbọ̀**

Ọ̀jọ̀gbọ́n Adétugbọ̀ ṣe àlàyé pé àwọn ẹ̀ka èdè Yorùbá tí ó wà ní ẹ̀yìn odi Nàìjíríà kò yàtọ̀ púpọ̀ sí èyí tí a ń sọ ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà., pàápàá jùlọ, ẹ̀ka èdè Ọ̀yó tí ó súnmọ́ Yorùbá àjùmọ̀lò jùlọ.

Ọ̀jọ̀gbọ́n yìí bá àwọn ènìyàn náà jíròrò ní ọ̀pọ̀ ìgbà. Ohun tí ó rí ni wí pé ní ọ̀pọ̀ ìgbà tí òun bá wà láàárín wọn, òun a máa gbàgbé pé kìí ṣe orílẹ̀ èdè Nàìjíríà láàárín àwọn Yorùbá ni òun wà. Èyí ṣeéṣe nítorí pé ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ wọn jọra púpọ̀ pẹ̀lú ti àwa tí a wà níbí.

Ní ọdún 2009, àwọn olùkọ́ èdè Yorùbá àti àwọn èdè mìíràn kórajọ pọ̀ sí ìlú Àbújá fún ọjọ́ mẹ́ta gbáko. Wọ́n ṣiṣẹ́ lórí àkọsílẹ̀ èdè Yorùbá níorílẹ̀ èdè Nàìjíríà – Republic of Benin, Togo àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. (Harmonisation of Yorùbá orthography (Nigeria, Republic of Benin and Togo). Iṣẹ́ náà ni CBAAC gbé jáde ní ìlú South African ní ọdún 2010.

Ní ọdún 2015, Olúwadọrọ̀ àti Abíọ́lá ṣe àbẹ̀wò sí Delta láti jíròrò pẹ̀lú àwọn olùkùmi tí ó wà níbẹ̀. Ẹ̀rí wọn ni wí pé ilé náà la wà nítorí pé a gbọ́ ara wa yé. Èdè Yorùbá gbayì púpọ̀.

**Ìwé ìtọ́kasí**


Adetugbo, A. (2001). *African Continuities in the Diaspora*. Lagos: The Centre for Black and African Arts and Civilisation, pp. 18-25.

Oluwadoro, J. O. and Abiola, A. (2016). “Olukumi: A Dialect of Yoruba in Diaspora”. *Papers in English and Linguistics (PEL),* Vol. 17, pp. 320-335.